# *Òfún Méjì A*

*Ifá pé ire bí a bá le rúbọ ẹ̀. Gbogbo ire ni eléyìun ọ́ nínú Odù yí.*

*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà*
*A díá fún Èjì Ọ̀ràngún*
*Èjì Ọ̀ràngún tí ́n sawo re ilé Ìlasàn*
*Ẹbọ n wọ́n ní ó ṣe*
*Ó sì gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ó rúbọ*
*Ìgbà Èjì Ọ̀ràngún sawo dé Ilé Ìlasàn la rájé*
*Eruku tóróró*
*Eruku tarara*
*Ìgbà Èjì Ọ̀ràngún sawo dé Ilé Ìlasàn la láya*
*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà*
*Ìgbà Èjì Ọ̀ràngún sawo dé Ilé Ìlasàn la ọ̀ọ́mọ*
*Eruku tóróró*
*Eruko tàràrà*
*Ìgbà Ejì Ọ̀ràngún sawo dé Ilé Ìlasàn la doníre gbogbo*
*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà.*

***Òfún Méjì A***
*Ifá desea bien a esta persona. Él debe ofrecer sacrificio. Todas las buenas cosas están viniendo a encontrarse con él.*

*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà.*
*Adivinación lanzada para Èjì Ọ̀ràngún*
*Que estaba aventurando el sacerdocio en la ciudad de Ìlasàn*
*Ellos le pidieron que realizara sacrificio*
*Él oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó*
*Era cuando Èjì Òràngún practicó su sacerdocio en la ciudad de Ìlasàn que nosotros tenemos esposas.*
*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà.*
*Era cuando Èjì Òràngún practicó su sacerdocio en la ciudad de Ìlasàn que nosotros tenemos niños.*
*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà.*
*Era cuando Èjì Òràngún practicó su sacerdocio en la ciudad de Ìlasàn que nosotros tenemos todas las cosas buenas.*
*Eruku tóróró*
*Eruku tàràrà.*

***Òfún Méjì B***
*Ifá pé òun pé ire gbogbo fún eléyìun, ṣùgbọ́n ká rúbọ.*

*Ení poro*
*Èjì poro*
*Èta poro*
*Èrin poro*
*Àrún poro*
*Èfà poro*
*Èje poro*
*Èjọ poro*
*A díá fún Ọpọ́n ayò*
*Èyi tí ń jẹ ní hòròhóróo káà mẹ́rìndínlógún*
*Ọmọ́ kún Inúu káà mẹ́rìndílógún òun báyìí?*
*Wọ́n ní ó rúbọ*
*Ó sì gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ó rúbọ*
*Ẹ wolé Ayò ẹ̀ wọmọ̀*
*A kì í bálé Ayò láìkún*
*Ẹ wolé ayò ẹ̀ wọmọ̀.*

***Òfún Méjì B***
*Ifá dice que él le desea todas las cosas buenas de la vida a esta persona Pero él debe ofrecer el sacrificio.*

*Ení poro*
*Èjì poro*
*Èta poro*
*Èrin poro*
*Àrún poro*
*Èfà poro*
*Èje poro*
*Èjo poro*
*Adivinación lanzada para Opón Ayò*
*El que estaba defendiéndose en dieciséis cuartos de alojo*
*'Los niños llenarían mi casa'? Él preguntó*
*Ellos le dijeron que realizara sacrificio*
*Él oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó*
*Venga y vea la casa de Ayò listo y vea a los niños en abundancia*
*Uno no puede encontrarse la casa de Ayò lista y vacía*
*Venga y vea la casa de Ayò listo y vea a los niños.*

***Òfún Ogbè A***
*Ifá pé ire fún eléyìun; ká rúbọ, a ò sì gbọdọ́ Sahún sí Obìnrin ẹni. Ifá pé kí eléyìun ó mọ́ bìínú o, ti wọn ò bá tîì lówó, kó mú sùúrù kó sì ní àforítì. Bí owó náà bá sì dé, kó ṣọ́ra kó mọ́ baà fi ìwàǹwára da orírun ajé náà rú pátápatá.*

*Igi Gbégbẹ ni ò léwé*
*Àfòmọ́ ni ò légbò*
*A díá fún  Míèéyè*
*A bù fún Ayaa rẹ*
*Nijọ́ ti wọ́n ń sunkún àwọn ò lajé lọ́wọ́*
*Àtọko àtìyàwó ni ọ́n pàwọn ò lajé lọ́wọ́*
*Ṣúgbọ́n kíké ti ọkọ́ ń ké*
*Ó pọ̀ ju ti Obìnrin ẹ̀ lọ*
*Ọkọ́ wáá ni àwọn adìẹ kan ti ń sìn*
*Ọ̀kan ńnú àwọn adìẹ ọ̀hún bá kú*
*Ọkọ́ bá bú púrú sẹ́kún*
*'Adìẹ ti òún gbẹ́kẹ̀ lé pàwọn ó tà'*
*Tàwọn ó mọ́ọ fowó ẹ̀ jẹun*
*Adìẹ ọ̀hún nàà lókú yìí!*
*Ó bá bẹ̀rẹ̀ síí ronú*
*Èṣù bá dé*
*Ó ní 'yan adìẹ nàà pamọ́'*
*Míèéyè bá yan adìẹ pamọ́*
*Ọjọ́ yí lu Ọjọ́*
*Oṣù yí lu Oṣù*
*Kùkùsajà wáá mú ọmọbìnrin Olókun*
*Ọmọ Olókun ò gbádùn*
*Olókun ba lọ̀ọ́ bá àwọn Awo ẹ̀*
*Wọ́n ní bó bá rí òkú adìẹ*
*Ọmọọ rè ó gbàádùn*
*Òkú adìẹ ni wọ́n e ṣètùtù fun*
*Wọ́n bá ń wá òkú adìẹ kíri*
*Èṣù ti ń ṣèhín ṣọ̀hún*
*Òún bá gbọ́*
*Ó bá sọ fún ọn pé òkú adìẹ ń bẹ nlée Méèéyè*
*'Míèéyè ni ẹ mọ́ọ wá lọ'*
*Nígbàa wọ́n e dé ilée Míèéyè*
*Èṣú ti débẹ̀*
*Ó ní sọ fún wọn pé igba ọ̀kẹ́ lọ́ọ́ ta adìẹ*
*Igba ọ̀kẹ́ ńjó ojó náà*
*Ẹrù owó ni*
*Lóòtọ́ àwọn ti ń wa òkú adìẹ dé*
*Wọ́n fiaba ọ̀kẹ́ lélẹ̀*
*Wọ́n gba adìẹ*
*Wọ́n bá lọ̀ọ́ fi ṣètùtù fọ́mọ Olókun*
*Ọmọ Olókun bá gbádùn*
*Nígbà ó tún ṣe sàà*
*Kùkùsajá tùn mú ọmọ Ọlọ́sà*
*Òun nàà rù ú*
*Ó sọ̀ ọ́*

*Wọ́n ní kóun náà ó mọ́ọ́ wá òkú adìẹ lo*
*Wọ́n tún júwe ilée Míèéyè*
*Adìẹ rẹ̀ kan ti tún kú*
*Ó tún yan án pamọ́ pé bóyá Ọlọ́un a jẹ́ ó tún rí bẹ́ẹ̀*
*Wọ́n tún san irú owó ti Olókun san*
*Igba ọ̀kẹ́ tún bọ́ sọ́wọ́ọ́ Míèéyè*
*Ó tún dà á sápò*
*Ṣùgbọ́n lẹ́ẹ̀kínní àti lẹ́ẹ̀kejì*
*Ìyàwóo Míèéyè ni wọ́n bá ńlé*
*Òun ní ó lọ́ọ́ pe ọkọ ẹ̀ wá*
*Pé ọ́n fẹ́ẹ́ ra òkú adìẹ*
*Míèéyè bá pa gbogbo owó tán*
*Kò fún Obìnrin ní nǹkan ńnú ẹ̀*
*Obìnrin bá ko bà*
*"Oko òun ò tiẹ̀ bun òun ní nǹkan ńnú owó yìí"!*
*Obìnrin Míèéyè náà bá mú ọ̀kan ńnú àwọn adìẹ tiẹ̀*
*Ó bá lù ú nó gbóńgó*
*Adìẹ bá kú*
*Ó bá yan án*
*Ó fi pamọ́*
*Ó tún pẹ́ sàà*
*Kùkùsajà tún dé sí ọmọ Olókun mìíìn*
*Olókun ní àwọ́n ti mọ ibi tàwọ́n tíí ra òkú adìẹ*
*Wọ́n bá tún kọrí sílée Míèyè*
*Èṣù ní sìí tẹ̀lé wọn*
*Ní gbogbo ìgbà ti wọ́n bá ń bọ̀*
*Bí ọ́n ti dé ibẹ̀*
*Obìnrin ni ọ́n tún bá ńlé*
*Obìnrin bá lọ́ọ́ mú adìẹ tiẹ̀ tó lù ní gbóńgbó pa fún wọn*
*Wọ́n ó mọ́ọ́ ka owó*
*Èṣù  ní ẹ dúó*
*Ńjé adìẹ yìí kú fúnraa rẹ̀ bí?*
*Torí ìmọ̀nràn lòun*
*Ó ti mọ nǹkan tó kú yàtọ̀ sí èyí ti ọ́n lù pa*
*Èṣù ní kí wọ́n ó fi adìẹ sílẹ̀*
*Obìnrin bá bú sẹ́kún*
*Nígbà ó dìgbàa tòún*
*Ni wọ́n kọ adìẹ sìlẹ̀*
*Ní ń hu bí ẹnii wọ́n dá lóró*
*Wọ́n ní 'a kìí forí wé Orí'*
*'Ìwọ lo fOrí araà rẹ wé ti Míèéyè ọkọ̀ọ̀ rẹ'*
*Ifá pé kí Obìnrin eléyìí ó mọ́ bìínú o*
*N ní wá ń jó ní wá ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Igi gbígbẹ ni ò léwé*
*Àfòmọ́ ni ò légbò*
*A díá fún Míèéyè*
*A bù falla rẹ̀*

*Nijọ́ ti wọ́n ń sunkún àwọn ò lajé lọ́wọ́*
*Ẹbọ n wón ní wọ́n ó ṣe*
*Míèéyè nìkán ló gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ló fòótọ́ rúbọ*
*Èèwọ̀ Òrìṣà*
*A kìí forí worí Míèéyè layé.*

***Òfún Ogbè A***
*Ifá desea bien a esta persona. Él debe ofrecer sacrificio no siendo avariento a su esposa; la esposa tampoco debe molestarse a las acciones de su marido estos días. Si ellos son presentemente pobres, ella debe ser paciente. Pero cuando las riquezas entran, ella debe advertirse para ejercer autodominio tal que su acción celosa no se arriesgaría la fuente de la riqueza permanentemente.*

*Es la madera seca que no tiene ninguna hoja*
*Las plantas parasitarias no tienen agujeros en las raíces*
*Adivinación lanzada para Míèéyè*
*También la adivinación lanzada para su esposa*
*En el día que ellos estaban llorando ellos no tienen riqueza hábil*
*El marido y la esposa estaban llorando que ellos son infelices*
*Pero el lamento del marido sin embargo*
*Está agonizando más que de su esposa*
*El marido cría algunos pollos locales como pájaros del libre-rango*
*Un día, uno de los pollos se murió*
*El marido reventó en las lágrimas*
*' Los pájaros en los que yo había lanzado todo las esperanzas '*
*' Que ellos generarían fondos después de venderlos '*
*' Qué nos alimentaría durante algunos días está muerto '*
*Él lloró amargamente y se preocupó a través de instintos de supervivencia*
*A ese punto, Èsù vino a él*
*' El asara el pollo y lo guarda ' Èsù dijo '*
*Míèéyè hizo como instruyó*
*Días rodados en días*
*Meses rodados en meses*
*Una enfermedad típica infligió a la hija de Olókun*
*Ella estaba enferma y postrada*
*Olókun fue a consultar con sus sacerdotes entonces*
*Ellos le dijeron que encontrara un pollo que se había muerto hace mucho tiempo*
*Sin que su hija no estuviera bien*
*' Es un pollo muerto que se usaría para realizar los ritos '*
*Ellos empezaron a echar una mirada alrededor de pollos muerto entonces*
*Pero Èsù, el espíritu que los transbordadores entre dos extremos contrarios*
*Oyó hablar del sacrificio*
*Él les dijo que un pollo muerto sólo pudiera encontrarse en la casa de Míèéyè*
*' Va y busque Míèéyè ' Èsù dijo*
*Antes de que los sirvientes llegaran a la casa de Míèéyè*
*Èsù habían estado allí*
*' Les dice usted vendería cada uno de los pollos para doscientas mil unidades de dinero '*
*Doscientos mil de unidades de dinero por esos días*

*Era mucho dinero*
*De verdad, los buscadores para el pollo muerto vinieron*
*Ellos sacaron doscientas mil unidades de dinero*
*A cambio del pollo*
*Ellos lo usaron a realizar los rituales para la hija de Olókun*
*Ella se curó del alimento*
*Después de otro momento breve de tiempo*
*El mismo tipo de enfermedad también infligió al niño de Olósà*
*Él demasiado rápidamente el pensamiento de una solución*
*Él consultó Ifá*
*Ellos también le dijeron que buscara pollo muerto*
*La casa de Míèéyè fue descrita de nuevo*
*Uno de los pollos de Míèéyè se había muerto entonces antes*
*Él lo disparó y también lo guardó en expectativa de otra suerte*
*Ellos vinieron y pagaron el mismo tipo de dinero pagado por Olókun*
*Otro doscientos mil en las palmas de Míèéyè*
*Él lo embalsillo*
*Pero en las primero y segundas ocasiones*
*Era la esposa de Míèéyè que ellos se encontraron en casa*
*Ella en los dos casos busco a su marido*
*Que hay algunas personas que quieren comprar pollos muertos*
*Míèéyè coleccionó todo el dinero*
*Él se negó a darle un diez centavos a la esposa*
*La mujer que se perturbó y se exclamó en tristeza*
*' Mi marido no compartió nada de este dinero ni siquiera conmigo '*
*Eso era cómo ella tomó uno de sus propios pollos*
*Y lo apaleó*
*El pollo se murió*
*Ella lo asó*
*Y lo guardó*
*Después de un periodo prolongado de tiempo*
*La misma enfermedad de la primera vez afectó a otro niño de Olókun*
*' Nosotros ya sabemos donde nosotros normalmente compramos los pollos muertos ',*
*Olókun dijo*
*Ellos se dirigieron directo hacia la casa de Míèéyè*
*El mismo Èsù que normalmente los sigue*
*Él también hizo las mismas cosas a este tiempo alrededor*
*Cuando ellos entraron en la casa de Míèéyè*
*Ellos se encontraron como de costumbre con la mujer*
*La mujer sacó rápidamente para el pollo que ella había apaleado a la muerte*
*Cuando ellos estaban contando el dinero*
*' Permítanos ser cautos ' Èsù dijo*
*' Es verdad que este pollo se murió por sí mismo '? Él razonó en sus corazones*
*Desde que él es un ser conocedor*
*Él podría distinguir el que se murió forma naturalmente a uno apaleado a la muerte*
*' Deje el pollo para ella ', Èsù dijo*
*La mujer reventó en las lágrimas*
*¿' Por qué debe estar en mi propio tiempo '?*
*¿' Por qué deben negarse a ellos comprar el pollo de mí este tiempo '?*
*Ella empezó a llorar profusamente*

*' Nadie usa un Orí para comparar otro '*
*' Usted es el del que más bien comparó su Orí con eso Míèéyè '*
*Ifá manda a la esposa de esta persona para no tener celos o molestia a su marido*
*Ellos empezaron a bailar y regocijar entonces*
*Ellos estaban alabando su Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Ellos dijeron que era como su Babaláwos había dicho*
*Es la madera seca que no tiene ninguna hoja*
*Las plantas parasitarias no tienen agujeros en las raíces*
*Adivinación lanzada para Míèéyè*
*También lanzada para su esposa*
*En el día que ellos estaban llorando ellos no tienen riqueza hábil*
*Es el sacrificio de riqueza que ellos les pidieron que realizaran*
*Era exclusivamente Míèéyè que eso oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó con verdad*
*¡Abominación de las Deidades!*
*Ningún hombre debe comparar su Orí con eso o Míèéyè*

***Òfún Ogbè B***
*Ifá pé kí  eléyìun ó rúbọ fún ìṣẹ́gun. Ire ńlànlá ń bọ̀ fún un; ṣùgbọ́n àwọn kan ó gbèé Ògún tì í.*

*Òfún nara, Òfún nara*
*Àjà nara pàtìpàtì*
*Awo Ikán ló díá fún Ikán*
*Èyí ti ń lọ rèé ṣẹ́ ọ̀tẹ̀ẹ̀ Kóóko*
*Kóóko àti Ikán ló gbogun ti araa wọn*
*Wón ní kí Ikán ó rúbọ*
*Ó bá rúa abẹ olójú méjì*
*Kóóko dúó gbáà*
*Ń retí àti bá Ikán jà*
*Eṣu bá kó abẹ méjì bọ Ikán lẹ́nu*
*Ikán bá ń gé Kóóko lẹ́sẹ̀*
*Ikán bá ṣẹ́ gbogbo ọ̀tẹ̀ẹ̀ Kóóko pátápátá*
*N ní wá ń jó n ní ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Òfún nara, Òfún nara*
*Àjà nara pàtìpàtì*
*Awo Ikán ló díá fún Ikán*
*Èyí ti ń lo rèé ṣẹ́ ọ̀tẹ̀ẹ̀ Kòòko*
*Rírú ẹbọ*
*Èèrù àtùkèsù*
*Ikán gbẹ́bọ ńbè*
*Ó rúbọ*
*Ẹ̀yin ò ri bí Ikán ti ń lo rèé ṣẹ́ ọ̀tẹ̀ẹ̀*
*Kóóko?*

***Òfún Ogbè B***
*Ifá le pide a esta persona que realice sacrificios a permitirle ganar; hay una fortuna grande que viene a él pero algunas personas se lo opondrían a ello.*

*Òfún nara, Òfún nara*
*Àjà nara pàtìtàtì*
*El Babaláwo de la Termita lanza adivinación para la Termita*
*El que iba a apagar la guerra fría montado por el Césped*
*El Césped y Termita estaban en nosotros al cuello*
*Ellos pidieron a la Termita realizar sacrificio*
*Él ofreció dos hojas afiladas*
*El Césped resistió un día arrogantemente*
*Esperando la muestra abajo con la Termita*
*Èsù inserto las dos hojas entonces como mandíbulas en la boca de la Termita*
*La Termita empezó a cortar el Césped ' las piernas*
*La termita ganó la guerra totalmente*
*La Termita empezó bailando y regocijando*
*Él estaba alabando su Babaláwo*
*Su Babaláwo estaba alabando Ifá*
*Él dijo que era como su Babaláwo predijo*
*Òfún nara, Òfún nara*
*Àjà nara pàtìpàtì*
*El Babaláwo de la Termita lanza adivinación para la Termita*
*El que iba a apagar la guerra fría montado por el Césped*
*Ofreciendo de sacrificios*
*Y regalos libres dados a Èsù*
*La Termita oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó*
*No pueda usted todos ver cómo la termita había tenido éxito apagando la guerra fría montada por el Césped?*

***Òfún Òyèkú A***

*Ifá pé òun pé ire fún eléyìun; Bò bá jẹ́ eléyìun ni wọ́n ṣe nǹkan fún tàbí ẹnìkan ní ó ṣe nǹkan fún un. Ire ńbè, ṣùgbọ́n kí wọ́n ó rúbọ. Nǹkan ìdíle kan tí wọ́n mọ́ ṣe ń bẹ nílé eléyìun. Ifá pé kò gbọdò jẹ́ kí nǹkan náà ó parun; kó mọ́ dìgbà kan nígbà ó bá yá, kí nǹkan òhún ó mọ́ mọ́ọ dà á láàmú.*

*Iṣú dápá tẹlẹ̀*
*Ó rìpó apá*
*Àkèré dápá tẹlẹ̀*
*Ó pòjò*
*Ọmọ kéré kèrè kéré níí ṣorò fàgbàlagbà*
*Kí wọ́n ó lè baà róhun mú jẹ*
*Àwọn ló ṣefá fún Òfún*
*Òfún ń lọ rèé tẹ Ẹnà fún Òyèkú*
*Tí wọ́n ó bàá tún ayé èèyàn ṣe*
*Òun làá pè ní Ẹnà títẹ̀*
*Orò yí là ń ṣe bí àwọn Babaláwo bá ta ọ̀ṣọ́ fúnfún*
*Òun náàni ọ́n ń ṣe ní ilẹ̀ẹ Mẹ́kà*
*Tí ọ́n bá sán aṣọ fúnfún*
*Nígbà tó kan pupa*
*Nígbà tó kan àyìnrín*
*Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ó ṣe ṣe orò yìí*
*Yóó sì jẹ́ ọ̀kànlénígba*
*Ẹni ó bá mọ gbogbo orò yíí ṣe pátápátá*
*Ifá ó mọ́ọ kan sáárá sí eléyìun*
*Èyuun lẹsẹ̀ Ilé ayé*
*Òfún ló wáá mọ̀ ó ṣe*
*Ó sì ń ṣe é fún Òyèkú*
*Ayé bèrè síí yẹ wọ́n*
*Orò yìí kan náà ni gbogbo wa ń ṣe*
*Ẹni ó bá jẹ onígbàgbọ́*
*Yóó loodò*
*Yóó ṣe ìtèbọmi*
*Wọ́n ó fun ní ọ̀ṣọ́ fúnfún*
*Ẹní ó bá jẹ Ìmọ̀le*
*Òun náà ó lọ mẹ́kà*
*Wọ́n ó sorò fún un*
*Bẹ́ẹ̀ náà ni lọ́dọ̀ Olọ́ya*
*Eléégún*
*Òòsà*
*Gbogbo Aláwo pátá*
*Ṣùgbọ́n ẹní ó bá yègẹ́ ńnúu tiẹ̀*
*Òun ní ó jẹ̀bi*
*N ni wọ́n wá ń jó n ni wọ́n ń yọ̀*
*Wọ́n ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Wón ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tàwọ́n wí*
*Iṣú dápá tẹlẹ̀*
*Ó rìpó apá*
*Àkèré dápá tẹlẹ̀*

*Ó pòjò*
*Ọmọ kéré kèrè kéré níí ṣorò fágbàlagbà*
*Kí wọ́n ó l`w baà ròhún mú jẹ*
*A díá fún Òfún*
*Èyí tí n lo rèé tẹ Ẹnà fún Ọ̀yẹ̀kú*
*Ajítenà Awo rere ni*
*Òfún ló tẹnà fỌ̀yẹ̀kú*
*Ajítenà Awo rere*

***Òfún Ọ̀yẹ̀kú A***
*Ifá desea bien a esta persona. Ifá dice cualquiera que esta persona ayudaría a alguien o que alguien lo ayudaría; todos están bien de cualquier manera. Ellos deben realizar sacrificio. La ancestral función conocida con esta familia que no debe permitirse morirse tal que no resultaría después en la vida que el espíritu ancestral los preocuparía.*

*La semilla de ñame germina después de plantar*
*Se vuelve un tubérculo grande*
*La rana en un asimiento (dominio, puño, agarrar, asir) equilibrado de la tierra*
*Lo requiere para llover*
*Los niños pequeños continuarían los ritos para el anciano*
*Tal que los Superiores encontrarían algo que comer después en la vida*
*Adivinación lanzada para Òfún*
*El que iba a poner un 'Enà' en Òyèkú*
*El acto de mejorar la vida de uno*
*Es que está llamando la inscripción de Enà*
*Éste es el rito observado cuando una antiojera (que se usa para tapar a los lados) de cortina blanca se cuelga por Babaláwos*
*Es la misma cosa que se hace en La Meca*
*Cuando ellos cuelgan la tela blanca*
*En otro momento estaría vuelta de una tela roja*
*Y también cuando es el giro para colgar el amarillo*
*Eso es cómo ellos realizaron sus propios ritos paso a paso*
*Sumaría doscientos y uno*
*Cualquiera que puede realizar todos estos ritos sin una mezcla*
*Ifá estarían orgullosos de esa persona*
*Porque es un paso importante de vida*
*Es Òfún que está sin embargo muy bien en esto*
*Él estaba haciéndolo entonces para Òyèkú*
*La vida los agradó a ambos*
*Es los mismos ritos y rituales que todos nosotros estamos haciendo*
*Él que es un cristiano*
*Iría al río*
*Él se bautizaría*
*Ellos le darían un pedazo blanco de tela*
*Él que es un musulmán*
*Él iría a La Meca*
*Los ritos se realizarían allí para él*
*Es las mismas cosas para el  devoto de Oya*

*Los devoto de la mascarada*
*Los devoto de Òòsà*
*Todos arman de cultos tradicionales*
*Pero quienquiera que los nota de un lapso en suyo propio*
*Recibiría el formulario del reproche de las Deidades en el cielo*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwos*
*Los Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que era como su Babaláwo había dicho*
*La semilla de ñame germina después de plantar*
*Se vuelve un tubérculo grande*
*La rana en un asimiento equilibrado de la tierra*
*Lo requiere para llover*
*Los niños pequeños continuarían los ritos para el anciano*
*Tal que los Superiores encontrarían algo que comer después en la vida*
*Adivinación lanzada para Òfún*
*El que iba a poner un 'Enà' en Òyèkú*
*Ajítenà es un sacerdote bueno*
*Era Òfún que puso un Enà sobre Òyèkú*
*Ajítenà es un sacerdote bueno*

***Òfún Òyèkú B***
*Ifá pé kì eléyìun ó rúbọ ọmọ tí ó nìí àánú lójú. Ọ̀ráan rẹ̀ ó dùn, ayé ó yẹ ́.*

*Ọ̀rúnmìlà wí ó ló di mọ́mọ́ jojo*
*Wọ́n ló di fẹ̀ẹ̀rẹ̀ i tìmọ́*
*Ọ̀rúnmìlà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Emi náà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Ifá ló sùn bíi kínni?*
*Wọ́n ló sùn bí àmú ọmọ ẹran*
*Ọ̀rúnmìlà lámùú ọmọ ẹran ò tí dùn tó áráárá*
*Ọ̀rúnmìlà wí ó ló di mọ́mọ́ jojo*
*Mo ló di fẹ̀ẹ̀rẹ̀ i tìmọ́*
*Ọ̀rúnmìlà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Emi náà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Ifá ló dùn bíi kínni?*
*Mo ló dùn bí àmú ọmọ eku*
*Ifá lámùú ọmọ eku ò tí dùn tó áráárá*
*Ifá wí ó ló di mọ́mọ́ jojo*
*Mo ló di fẹ̀ẹ̀rẹ̀ i tìmọ́*
*Ọ̀rúnmìlà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Emi náà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Ifá ló dùn bíi kínni?*
*Wọ́n ló dùn bí àmú ọmọ ẹja*
*Ifá lámùú ọmọ eja ò tí dùn tó áráárá*
*Ọ̀rúnmìlà wí ó ló di mọ́mọ́ jojo*
*Wọ́n ló di fẹ̀ẹ̀rẹ̀ i tìmọ*
*Ọ̀rúnmìlà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Emi náà ló dùn jọ̀jọ̀*
*Ifá ló sùn bíi kínni?*

*Wǫ́n ló dùn bí àmú ọmọ ẹyẹ*
*Òrúnmìlà lámùú ọmọ ẹyẹ í tì dùn tó áráárá*
*Òrúnmìlà wí ó ló di mọ́mọ́ jojo*
*Mo ló di fẹ̀ẹ̀rẹ̀ i tìmọ́*
*Òrúnmìlà ló sùn jọjọ*
*Emi náà ló dùn jọjọ*
*Ifá ló dùn bíi kínni?*
*Mo ló dùn bí àmú ọmọ ẹni*
*Ifá ni mo ṣeun ṣeun*
*Ifá pé àmú ọmọ ẹni ló dùn*
*Ó lámùú ọmọ eku ò tí dùn áráárá*
*Ó lámùú ọmọ ẹja ò tí dùn áráárá*
*Àmú ọmọ ẹyẹ ò tí dùn áráárá*
*Àmú ọmọ ẹranko ò ti dùn áráárá*
*Amú ọmọ ẹ̀nìyàn ò ti dùn*
*Àmú ọmọ ẹni ló dùn ló jóyin lọ*
*Ọmọ ló ti dùn ló jóyin lọ*
*Ọmọ ló ti dùn*
*Ọmọ ju àmú*
*Ọmọ ló ti dùn ló jóyin lọ*

***Òfún Òyẹ̀kú B***
*Ifá le piden a esta persona que ofrezca sacrificio para un niño benévolo. Sus cosas estarían bien.*

*Òrúnmìlà le dijo simplemente aclarando (avivar, aclarar, abrillantar)*
*Yo dije que es hasta sobre el alba*
*Òrúnmìlà dijo que es muy dulce*
*Yo también dije que es dulcemente la bebida preparada*
*¿Es tan dulce como qué? Ifá preguntó*
*Ellos dijeron que es tan dulce como la leche en el pecho de un animal*
*Ifá dijo que el pecho de un animal no es como dulce*
*Ifá dijo que simplemente está aclarando*
*Yo dije que es hasta el alba*
*Òrúnmìlà dijo que es muy dulce*
*Yo también dije que es dulcemente la bebida preparada*
*¿Es tan dulce como qué? Ifá preguntó*
*Yo dije que es un dulce como la leche del pecho de una rata*
*Ifá dijo que el pecho de una rata no es como dulce*
*Òrúnmìlà le dijo simplemente aclarando*
*Yo dije que es hasta sobre el alba*
*Òrúnmìlà dijo que es muy dulce*
*Yo también dije que es dulcemente la bebida preparada*
*¿Es tan dulce como qué? Ifá preguntó*
*Ellos dijeron que es tan dulce como la leche del pecho de un pez*
*Ifá dijo que el pecho de un pez nunca es como dulce*
*Òrúnmìlà le dijo simplemente aclarando*
*Yo dije que es hasta sobre el alba*
*Òrúnmìlà dijo que es muy dulce*
*Ellos también dijeron que es dulcemente la bebida preparada*

*¿Es tan dulce como qué? Ifá preguntó*
*Ellos dijeron que es un dulce como la leche del pecho de un pájaro*
*Ifá dijo que el pecho de un pájaro no es como dulce*
*Òrúnmìlà le dijo simplemente aclarando*
*Yo dije que es hasta sobre el alba*
*Òrúnmìlà dijo que es muy dulce*
*Yo también dije que es dulcemente la bebida preparada*
*¿Es tan dulce como qué? Ifá preguntó*
*Yo dije que es tan dulce como la leche del pecho del niño de uno*
*Muchas gracias, Ifá dijo*
*Ifá dice el pecho del niño de uno es el más dulce*
*Él dijo que el pecho del niño de la rata no es como dulce*
*El pecho del niño del animal no es como dulce*
*Pero el pecho del niño de Hombre es el que es dulce*
*El pecho del niño de Hombre es el que es dulce*
*El niño es más dulce que miel*
*El niño es uno  que es dulce*
*El niño es mayor que la dulzura del pecho*
*El niño es más dulce que miel*

***Òfún Ìwòrì A***
*Ire púpọ̀ wà fún eléyìun tí bá ń hùwà rere. Ifá pé òmìmì kán ń bọ̀ tó nílò ààtò tó yanjú gidigidi kó tóó dára. Èrò tí eléyìun ní nínú lásìkò yí dára púpọ̀ ṣùgbọ́n kó mọ́ọ gbọ́rọ̀ yàn.*

*Òfún lawo ìgándó*
*Ìwòrì lawo ìgándò*
*Ọ̀ràn gándo gàndo ò tán ́nlẹ̀ yí bọ̀rọ̀ bọ̀rọ̀*
*A díá fún àgbàágbà mẹ́fà*
*Èyí tí gbogboo wón rojọ́ ẹnuu wọn*
*Tí gbogbo wọn ó sì mọ́ọ jàre*
*Wọ́n ní kí wọ́n ó rúbọ*
*Wọ́n ní òmìmì kán ń bọ̀ wáá mì wọ́n*
*Ọ̀ká lẹni àkókó*
*Ńnú àwọn àgbàágbà ló wà*
*Kèé sìí sún mọ́ èèyàn*
*Gbogbo nǹkan tó bá sún mọ́*
*Gbogboo wọ́n ni wọ́n ó họ fún un*
*Òkété lẹnìkejì*
*Ọ̀kẹ́rẹ́ nìkẹta*
*Èlulùú lẹnìkẹrin*
*Àparò Ọ̀yẹ̀yẹ̀ lẹni ìkarùún*
*Àáyá lẹnìkẹfà*
*Gbogboo wọn ni wọ́n jọ ń gebé láì síyọnu*
*Wọ́n níwọ Òkété rúbọ*
*Kóo mọ́ baà rí ogun àwọlébá*
*Òkété ní kín ní ń jẹ́ ẹbọ àwọlébá?*
*Nígbà ó di òsán ọjọ́ kan*
*Ọ̀ká ń wá nǹkan tí ó jẹ kíri*
*Ló bá di wòò ńnú Ilé Òkété*
*Bí Òkété ṣe fojú kan ọ̀ká*
*Kín ló dí òun mọ́lé yìí?*
*Ló bá jáde fòtì*
*Ọ̀kẹ́ré bá rí Òkété lóde òsán*
*Èèwọ́!?*
*A kìí réwú lóde òsán*
*Ọ́kẹ̀rẹ̀ bà sáré gorí igi Ìrókò*
*Ó lójú òhun ò níí níkàn ríbi*
*Sáá sáá sá fò n lọ̀kẹ́rẹ́ ń ké*
*Èlulùú gbọ́*
*Òun náà figbe ẹ̀ẹ̀mo bẹnu*
*Èjẹ́ ru lẹyẹ oko ń ké*
*Èlulùú ní 'ó ṣeéṣe kí òrẹ́ òun ti rí nǹkan ewú ló fi ní kóun ó fò'*
*Àparò Ọ̀yẹ̀yẹ̀ gbọ́ lóko*
*Òun náà bá figbe bọnu*
*Ìlú ra*
*Àáyá gbó tí Àparò ń ké pé ìlú ra*
*Híhọ lÀparò  họ*
*I balanga; I balanga*
*Àáyá kọlu èyin Ẹtù*

*Èyin Ẹtù fọ́*
*Ẹtù bá fò*
*Ó bóórí igi*
*Ní bá ń ké*
*Ẹ pé è*
*Nǹkán ti bàjẹ́*
*Ìlú ẹ pé è*
*Wọ́n bá pe gbogbo ìlú jọ́*
*Kín lẹ a rí o?*
*Ìwọ Ẹtù kín lo pe àwọn fún?*
*Ẹtu lóun ò mọ ibi tí Àáyá ti wá*
*Gbogbo èyin òun ló ti fọ́ tán*
*Wọ́n ní kí wọ́n ó lọ́ọ́ pé Àáyá wá*
*Àáyá kín ló dé tóo fi fọ́ èyin Ẹtu?*
*Àáyán ní nígbà tí òún ń gbọ́ pé ìlú ra*
*'Ìlú ra'*
*Bógun ò bá sì dé*
*Ẹnìkan a lè mọ́ọ ké pé ìlú ra bí o?*
*Taa ló a pé ilú ra fún ọ?*
*Ó ní Àparò ọ̀yèyẹ ni*
*Wọ́n ní wọ́n ó pe Àparò wá*
*'Éése o Àparò'?*
*Òun náà ní nígbà tòún náà gbọ́ tí Èlulùú´nké ẹ̀jẹ́ ru*
*Ẹ̀jẹ́ ru lòón gbọ́ tóun fí ń kígbe bẹ́ẹ̀*
*Ìwọ Èlulùú kín ló dé?*
*Èlulùú ní nígbà tóun gbọ́ tí Ọ̀kéré ń ké*
*Ọ̀kẹ́rẹ́ ń ké pé kóun ó sá fò 'sá sáá sá fò'*
*Sáá sáá sá fò*
*Ọ̀kẹ́rẹ́ kín lo rí o tóo fi pé kí Èlulùú ó fò?*
*Òun náà ní nígbà tòún rí Òkété lóde ọ̀sán*
*TÒkété è é sìí jáde ọ̀sán*
*Lòún sì ri tí Òkété´n sáré àsápajúdé*
*N náà ló mú òun tóun fí ń ké*
*Ìwo Òkété bóo ló ṣe jẹ́ tẹ́ẹ́ fi jáde lọ́sàán gangan?*
*Òkété ní jẹ́ẹ́jẹ́ òun lòún jókòó*
*LỌ́ká bá wá káun mọ́lé*
*BỌ́ká bá sì ká èèyàn mọ́lé*
*A wa mọ́ọ rọrùn bí?*
*Ìwọ Ọ́ká kín ló ń wá ńnú ilé Òkété?*
*Oká ní òún ń wá nǹkan tí òún ó jẹ kíri ni*
*Òun òsá mọle ẹníkan yàtọ̀*
*Gbogbo àwọn tí ń bẹ ńbẹ̀ kọ hà!*
*Taa la wá rí dá ẹ́bi´nnúu yín?*
*Ifá pé ká má ṣe àṣìgbọ́ ọ̀rọ̀*
*Ká mọ́ọ wádìí ọ̀rọ̀ dáadáa ká tóó ṣe òhúnkòhún*
*Ẹtú ló pe gbogboo wọn jọ*
*Ará bá tu gbogboo wọn*
*N won wá ń jó ní wón á ń yọ̀*
*Won ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*

*Wón ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tàwọ́n wí*
*Òfún lawo ìgándó*
*Ìwòrì lawo ìgándò*
*Ọ̀ràn gándo gàndo ò tán ńlẹ̀ yí bọ̀rọ̀ bọ̀rọ̀*
*A díá fún àgbàágbà mẹ́fà tí gbogboo wọ́n rojọ́ ẹnuu wọn*
*Gbogboo wọ́n rojọ́ ẹnuu wọn*
*Wọn ò níí lẹ́bi*
*Ọpẹ́lọpẹ́ ẹtú ló jára ó tù wá*
*Àwá dẹni ọlà pẹ̀rẹ̀gẹdẹ.*

***Òfún Ìwòrì A***
*Esta persona tendría bultos (manojo) de fortunas buenas si él podría compartir haciendo bien. Un caso raro va a presentarse pronto y necesitaría que un proyectista muy inteligente ejecutara. Él se exhorta no interpretar mal las instrucciones y debe comportarse bien.*

*Òfún es el Babaláwo de Ìgándó*
*Ìwòrì es el Babaláwo de Ìgándó*
*La saga de malas interpretaciones se negaría a acabar fácilmente en esta tierra*
*Adivinación lanzada para seis superiores*
*Todos de quién enternecerían (ablandar, ofrecer, tender) su caso*
*Y todos ellos se vindicarían*
*Ellos les pidieron para ofrecer el sacrificio*
*'Hay una prueba ácida acechando y viniendo a probarlos a todos' ellos dijeron*
*La Cobra en su propia magnanimidad es la primera persona*
*Él está entre los seis superiores*
*Él no va a nadie casi*
*Todos los animales que lo ven dentro de su vecindad*
*Ellos tendrían que tomar a sus talones*
*La rata grande es el segundo*
*La ardilla es el tercero*
*El pájaro de Èlulùú es el cuarto*
*El ave del arbusto es el quinto*
*El chimpancé es el sexto*
*Todos ellos estaban viviendo juntos sin rencor*
*'Usted, la rata grande, ofrezca sacrificio'*
*'Tal que un intruso diabólico no vendría a usted' ellos advirtieron*
*'Yo no cuido de cualquiera tipo intrusión' la rata grande contestó'*
*En un día fatal*
*La Cobra estaba buscando intensamente a través del bosque*
*Él entró accidentalmente en el túnel de la rata grande*
*Inmediatamente la rata grande lo vio*
*'¿Qué tipo de problema es esto?'*
*Él corrió fuera a través de la puerta trasera*
*La Ardilla vio la rata gigante en la media tarde*
*'¡Una aberración!'*
*Es una rareza para ver la rata gigante en la luz del día*
*Él subió el árbol de Ìrókò rápidamente*
*'Yo no sería el único para ver esta divergencia'*
*'Salga volando', él lloró*

*El pájaro de Èlulùú oyó esto de al otro lado*
*Él levantó la alarma también*
*'Sangre está brotando' él lloró*
*'Ése debe ser mi amigo que me pide que desollara fuera de en la anticipación de peligro' Èlulùú razonó*
*El ave del arbusto de su situación oída*
*Él salió volando oyendo a su amigo Èlulùú que grita con la urgencia inaudita también*
*'¡El Chimpancé de dónde él estaba comiendo escucho 'la ciudad que está en ruinas!*
*Él tomó derecho a sus talones*
*Él galopó lejos en una carrera*
*El Chimpancé caminó entonces equivocadamente en los huevos del ave de guinea*
*Él rompió los huevos de ave de guinea mientras el último estaba fuera de su sitio de incubación*
*El ave de guinea voló fuera*
*Y aterrizó en una cima del árbol*
*Él gritó*
*'Reúnanse'*
*'El estrago se ha hecho'*
*'Todos los habitantes de ciudad deben congregar para escuchar a mi petición'*
*Ellos llamaron en todas las personas*
*'Que es el problema'? Las personas preguntaron*
*'¿Por qué usted nos ha llamado en una asamblea?'*
*'Yo no sé lo que salió mal con el chimpancé'*
*'Él ha roto todos mis huevos ' El ave de guinea se quejó*
*Ellos pidieron al chimpancé a ser llamado*
*'¿Usted el chimpancé, por qué usted tiene que romper los huevos del ave de guinea?'*
*'Yo oí alguien gritando que la ciudad esta arruinada*
*'La ciudad está en ruinas*
*'Si no es el tiempo de guerra'*
*'Habría a alguien gritar como a tal'? Preguntó al chimpancé*
*'Quién estaba gritando como a tal'? Las personas preguntaron*
*'Era el ave del arbusto' dijo el chimpancé*
*Ellos enviaron pro el ave del arbusto*
*'Por qué si usted debe levantar una alarma falsa' ellos preguntaron*
*'Cuando yo oí pájaro de Èlulùú que bravea 'sangre está brotando'*
*'¿El pájaro de Èlulùú está braveando sangre está brotando?'*
*'¿Usted Èlulùú, por qué usted debe hacer eso?'*
*'Bien, yo oí la gritería de la ardilla*
*'Él estaba diciéndome que yo debo salir volando rápido'*
*'Salga volando; salga volando' Él me había dicho*
*¿Usted ardilla, por qué usted necesita decirle que salga volando?*
*Yo vi la rata gigante en el medio de la tarde*
*'Cuando todos nosotros sabemos que la rata gigante ordinariamente no debe salir durante el día'*
*Yo vi la rata gigante en un golpe de su vida con su cola apuntada al cielo*
*Ésa fue la razón por qué yo he tenido que sonar una alarma*
*¿Usted la rata gigante ' por qué usted necesita salir en el medio del día?'*
*Yo fui por qué en mi túnel descansando, la rata gigante dijo*
*'Yo vi la Cobra que entra en mi túnel entonces'*
*'Y si una cobra debe entrar en el casa uno vive'*

*'Cómo fácil eso sería'? La rata gigante concluyó*
*'¿Usted Cobra, por qué usted debe entrar en la casa de la rata grande?'*
*'Yo estaba buscando algo que comer' la Cobra simplemente dijo*
*'Yo no conozco la casa de alguien'*
*Todas las personas presentes exclamaron en la confusión*
*'¿Quién nosotros condenamos ahora como culpable?'*
*Ifá nos pide que no interpretemos mal las instrucciones*
*Nosotros debemos investigar concluyentemente antes de actuar*
*Es el ave de guinea que congregó a todos*
*Y todos ellos se aplacaron*
*Ellos empezaron a bailar y regocijar entonces*
*Ellos estaban alabando su Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Ellos dijeron que era como su Babaláwos había dicho*
*Òfún es el Babaláwos de Ìgándó*
*Ìwòrì es el Babaláwo de Ìgándó*
*La saga de malas interpretaciones se negaría a acabar fácilmente en esta tierra*
*Adivinación lanzada para seis superiores que enternecerían (ablandar, ofrecer, tender) su caso*
*Ellos enternecieron sus casos individuales*
*Todos ellos fueron vindicados*
*Gracias a El ave de guinea que nos había hecho calmar*
*Nosotros nos volvemos personas de riquezas ahora en la multitud*

***Òfún Ìwòrì B***
*Ifá pé kí eléyìun ó fi fìlà tí ń bẹ lórí ẹ rúbọ kí wọ́n ó mọ́ baà fì ète tí ò níláárí lé e jáde ńlé ẹ. Ifá pé kí wọ́n ó sọ́ alejó tí wọ́n ó bàá gbà mó baà kó bá wọn. Ifá pé òún pé ire.*

*Òfún níí sawo Ìgándó*
*Ìwòrì lawo Ìgándó*
*Ọ̀ràn gándo gándo ò tán´nlẹ̀ yí bọ̀rọ̀ bọ̀rọ̀*
*Adíá fún Ewú*
*Èyí tíí sọmọ Oní fìlà òdòdò*
*Wọ́n ní kí Ewú ó rúbọ*
*Wọ́n ní fìlà òdòdó tí ń bẹ lórí ẹ lẹbọ*
*Ewú bá ń wò wọ́n níran*
*Wọ́n ní ìwọ Ewú rúbọ*
*Bóò bá rúbọ*
*Wọ́n ó gbòǫ́n ọ jùnù ńnú Iléè rẹ*
*Ewú kọ̀*
*Ewú ò rú*
*Abẹ̀ ògán ni Ewú sì fi ṣe fìlà òdòdó tí ń bẹ lórí ẹ*
*Ikán ló sì ni ògán*
*Tó bá ti kóólé tí ọ́n sì rí ipasẹ̀ẹ rẹ lẹ́nu ògán*
*Wọn a pé Ewú ń bẹ ńnúu kinní yìí*
*Wọ́n ó bàa bẹ̀rẹ̀ síí hú ògán*
*Gbogbo kùnmọ̀ ní wọ́n ó kòó bò ó*
*Èṣù a ní ń bẹ ńnu Ilé*
*'Ẹ mọ́ọ hú u'*
*Nígbàa wọ́n bá hú ògán*

*Ewú ó bàá fò jáde fòtì*
*Wǫ́n ní nígbà tí ǫ́n ti hú òdòdó tí ń bẹ lórí ẹ̀*
*Dandan ni kó jáde*
*Àyìn ẹ́yìn ní ń yin àwọn Babaláwo è¸*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Òfún níí sawo Ìgándó*
*Ìwòrì lawo Ìgándò*
*Ọ̀ràn gándo gándo ò tán´nlè yí bọ̀rọ̀ bọ̀rọ̀*
*A díá fún Ewú tíí sọmọ onífìlà òdòdó*
*Wǫ́n ní kí Ewú ó rúbọ kó mọ́¸ baà sá jáde ńnú Ilé*
*Ewú gbẹ́bọ bẹ́ẹ̀ ni ò rúbọ*
*Gìrí lọ̀gán torí jìn*
*Ewú wáá jáde lọ*

***Òfún Ìwòrì B***
*Ifá le pide a esta persona sacrificar una gorra (gorro, bonete, birrete, casquete) tal que las personas no conspirarían para cazarlo fuera de su casa. Ifá advierte a esta persona para notar el tipo de visitantes para entretener (agasajar, divertir, abrigar, consideración) tal que ellos no lo traerían mal.*

*Òfún es el Babaláwo de Ìgándó*
*Ìwòrì es el Babaláwo de Ìgándó*
*La saga de malas interpretaciones se negaría a acabar fácilmente en esta tierra*
*Adivinación lanzada para la Rata gigante*
*El niño con una gorra florida*
*Le pidieron que realizara sacrificio*
*'La gorra florida en su cabeza es el sacrificio'*
*La rata gigante miraba hacia abajo sobre ellos con el desprecio*
*'Usted la rata gigante, ofrezca sacrificio' ellos advirtieron de nuevo*
*'Si usted se niega'*
*'Ellos lo cazarían fuera de su casa con la ignominia'*
*El gigante se negó*
*Él no ofreció el sacrificio*
*Sin embargo dentro del molde de la colina es gorra florida conocida con la rata gigante*
*'La termita es el que poseyó la colina'*
*Una vez que él entró y sus huellas vistas*
*'La rata gigante esa dentro' el Hombre diría*
*Ellos empezarían a desmantelar la colina*
*Ellos atacarían con los garrotes y hachas*
*'Él esta dentro'! Èsù les dirían*
*'Continua desmantelándolo'*
*Después de llegar a la base*
*La rata gigante saltaría fuera en un destello (llamarada, ráfaga)*
*'Después de que la gorra florida en su cabeza ha estado alejado'*
*'Él saldría definitivamente'*
*Él empezó alabando sus Babaláwos tardíamente*
*Él dijo que era exactamente como sus Babaláwos había dicho*
*Òfún es el Babaláwo de Ìgándó*
*Ìwòrì es el Babaláwo de Ìgándó*

*La saga de malas interpretaciones se negaría a acabar fácilmente en esta tierra*
*Adivinación lanzada para la Rata gigante que tiene una gorra florida*
*Le pidieron realizar sacrificio tal que él no se cazaría fuera de su casa*
*La rata gigante oyó hablar todavía del sacrificio no lo consideró*
*Inesperadamente, la colina de la termita dio el camino de la cima*
*La rata gigante dejó su casa humillada.*

***Òfún Òdí A***

*Ifá pé kí eléyìun ó kílọ fún ìyàwó è, torí yóó bìí àmí ọmọ̀kan. Àgbà ọmọ̀lọmọ̀náà; ọmọ̀ tó jẹ́ pé láti ọjọ́ ti ọ́n bá ti bí I sílẹ̀ ní ó ti mọ́ọ gbọ́rọ ti ọ́n bá ń ṣo. Kò kàn níí lè dá èsì padà ni.*

*O fúndìí*
*Ò ń dó*
*O sòrò*
*O ò bẹ̀bẹ̀*
*O sì tún ní kí wọ́n ó gbé oníkòjú wá*
*A díá fún Purọ́purọ́ alẹ́ àná*
*Èyí ti ó dọ́jà ti ó purọ́ mọ́ ọmọọ rẹ̀*
*Ìyá àgbà purọ́purọ́ ló dé ọjà*
*Ló sì pọn ọmọ ẹ̀ lọ*
*Nígbà ó dé àárin ọjà*
*Bó ti bẹ̀rẹ̀ kó mọ́ọ ra ọjà*
*Àfi pùú*
*Ló bá só*
*Sísó tó só báyìí*
*Pàá, ló gbá ọmọ ẹ̀ nídìí*
*Ó níwọ ọmọ yìí*
*Lò sì wáá só pa gbogboo wa báhun*
*Ọmọ́ bá gbọ́*
*Òun níyá òún purọ́ mọ́ tó bayìí?*
*Ọmọ́ bá bú sẹ́kún*
*Wọ́n e wọlé*
*Ọmọ́ sunkún sunkún*
*Ọmọ ò tún dákẹ́*
*Wọ́n wáá ṣe ṣee ṣe*
*Bóo làwọn ó ti wáá ṣe?*
*Wọ́n bá tọ Òrúnmìlà lọ*
*Gba àwọn dákun!*
*Àwòyeróye Awo Ilé Òrúnmìlà*
*Ó ní 'Ìwọ ìyá yìí lo ṣe ihun ti ọmọ́ fí ń sunkún'*
*'Ó ní kínni kan tóo ṣe fún ọmọ yìí ni kóo yáa rántí'*
*Ìyá rántí rántí*
*Ó ní àfi lọ́ja náà ni*
*Tóun gbé só làárin gbogbo èèyàn*
*Tóun ní ọmọ yìí ló só*
*Òrúnmìlà ní 'O ó tùún padà lọ ọjà ọ̀hún'*
*'Kó o wáá mọ́ọ fẹnu araà rẹ wí'*
*'Pé Onísó alẹ́ àná tó só'*
*'Ọmọ kọ́ o'*
*'Èmi ni mo só o'*
*Ọmọ òun kọ́ o*
*Òun lòún só o*
*Ìyá bá padà lọ ọjà*
*Ní bá ń pé gbogbo ará ọjá*
*Isó alẹ́ àná*
*Òun lòón só o*

*Kéè ṣe ọmọ òun o*
*Ọmọ́ bá dákẹ́ ẹkún*
*Ó lóo fúndìí*
*Ò ń só*
*O sọ̀rọ̀*
*O ò bẹ̀bẹ̀*
*O sì tún ní kí wọ́n ó gbé oníkòjú wá*
*A díá fún Purọ́purọ́ alẹ́ àná*
*Èyí ti ó dọ́jà ti ó sòó tán*
*Ti ó purọ́ mọ́ ọmọọ rẹ̀*
*Onísó alẹ́ àná o*
*Ìyá mọ̀mọ̀ ló só o*
*Ọmọọ rẹ̀ mọ̀mọ̀ ká o*
*Onísó alẹ́ àná*

***Òfún Òdí A***
*Ifá desea bien a esta persona. Él debe advertir a su esposa porque ella tendría un niño que oiría y comprendería todos los discursos dirigidos a él, pero no puede ser capaz de responder.*

*Usted contrajo su ano*
*Y usted se peyó (echo un pedo)*
*Usted habló en una calumnia (crítica, murmurar)*
*Usted no se disculpó*
*Usted incluso les pidió que llamaran a un testigo confrontando*
*Adivinación lanzada para el Mentiroso de la noche de ayer*
*El que llegaría al mercado y quedaría sobre su niño*
*Esta mujer particular llego el mercado*
*Ella tiene su bebe en su espalda*
*Cuando ella llegó a un establo*
*Donde ella normalmente compra sus cosas*
*Ella dobla abajo, y en un poco pero la explosión audible (perceptible)*
*Ella se peyó*
*En cuanto ella comprendiera a las personas cerca de oyó su peyó*
*Ella dio una bofetada al bebé sobre su espalda*
*'Usted este niño pequeño'*
*'Usted se peyó tanto' ella lo acusó*
*El niño en su espalda oyó esto*
*'¿Mi madre había mentido contra mí mucho?'*
*El niño reventó en un chillón de lamentos*
*Para la duración del período ellos se quedaron en el mercado y su jornada a casa*
*El niño todavía estaba llorando*
*Él se negó a detener los gemidos*
*Ellos entraron en la casa hasta la tarde del mismo día*
*El niño no detuvo*
*Ellos probaron todas las clases de vicios para pacificar al bebé sin efecto*
*'Qué nosotros vamos hacer'? Los padres preguntaron apenados*
*Ellos decidieron consultar Òrúnmìlà*
*'¡Ayúdenos!'*
*Debido a la exposición mágica, el sacerdote de la casa de Òrúnmìlà*

*'Es usted la madre que es la causa' Òrúnmìlà dijo*
*'Intenta recordar que exactamente usted hizo a él'*
*La mujer intentó recordar todos sus actos al niño*
*Ella dijo 'excepto en el mercado ayer'*
*'Donde yo me peí (echar un pedo) en medio de las personas'*
*'Y mintió era mi niño'*
*'Usted tendría que regresar al mismo mercado', Òrúnmìlà dijo*
*'Usted confesaría alto y diría repetidamente con su boca'*
*'Que la persona que se peyó (echo un pedo) ayer'*
*'No era el niño en su espalda'*
*'Era usted' Òrúnmìlà concluyó*
*'No era mi niño que se peyó'*
*'Era yo'*
*La madre regresó entonces al mercado*
*Sin perder tiempo llamado a todos la atención*
*'La flatulencia de la noche de ayer'*
*'Era yo que lo hizo'*
*'No era mi niño'*
*El niño detuvo el grito abruptamente*
*Ella dijo 'Usted contrajo su ano'*
*Y se peyó*
*Usted habló en una calumnia*
*Usted no se disculpó*
*Usted incluso les pidió que llamaran a un testigo para confrontarlo*
*Adivinación lanzada para el Mentiroso de la tarde de ayer*
*El que llegaría al mercado y peyó*
*Y mentira que era su niño*
*La persona que se peyó ayer tarde*
*Realmente era la madre*
*No era el niño*
*La persona que causó la confusión la noche de ayer*

***Òfún Òdí B***
*Ifá pé eléyìun ń bèèrè ajé; ajé náà ó sì yọ sí i. Bí eléyìun bá jẹ́ Awo tí ọ́n sí gbé aláàárẹ̀ tọ̀ ọ́ wá, Kó ṣètùtù dáadáa kó mọ́ lọ̀ọ́ wo aláàárẹ̀ sàn tán, kí wọ́n ó mọ lọ̀ọ́ dà nnkan síl̀ẹ̀ fun.*

*Ọdán ojúde abìji rẹ̀rẹ̀èrẹ̀*
*A díá fún Iná*
*Èyí ti ń lọ rèé wo Olókùnrùn yè*
*Wọ́n ní kó rúbọ*
*Nígbà ìwásẹ̀*
*Iná ni ọ́n fíí wo Òkùnrùn*
*Ti Òkùnrùn bá ti mú wọn*
*Wọ́n ó dàá iná yá*
*Èjẹ̀ẹ wọ́n ó mọ́ọ yọ́*
*Bí ẹ̀jẹ́ bá ti ń yọ́*
*Wọ́n ó mọ́ọ mu òògùn*
*Àrùn ó mọ́ọ dínkù*
*Wọ́n ní ìwọ Iná rúbọ kí wọ́n ó mọ́ baà kọjú dà ọ́*

*Wọ́n ní rúbọ àwọn Elénìní*
*Iná lóun?*
*Bóun ti tóbi tó yìí?*
*Kín lóùn ó fi ẹbọ ṣe?*
*Omi àti Iná ò sì rẹ́*
*Wọ́n bá lọ́ọ́ bẹ omi lọ́wẹ̀*
*Bí Inábá sì wo Olókùnrùn yè tán*
*Wọ́n ó bàá bu omi pa Iná*
*Ibi ni ọ́n fi ṣu Iná*
*Àyìn éyìn ni Iná ń yin àwọn Babaláwo ẹ̀*
*Ní wá ń jó ní ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Odán ojúde abìji rẹ̀rẹ̀èrẹ̀*
*A díá fún Iná*
*Èyí ti ń lọ rèé wo Olókùnrùn yè*
*Wọ́n ní kó rúbọ*
*Kó rúbọ kó tóó wo Òkùnrùn*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò fẹ́*
*Iná wáá wo Òkùnrùn tán o*
*Wọ́n wáá padà pa Iná pátápátá*

***Òfún Òdí B***
*Ifá dice que esta persona está preguntando por riqueza. Si él es doctor o un Babaláwo, una persona enferma se llevaría a él; Ifá le implora que realice bien el sacrificio tal que después de curar el enfermo, la persona curada o su familia no regresarían causarle estrago.*

*El árbol de Odán en espacio libre fuera con una sombra ancha*
*Adivinación lanzada para el Fuego*
*El que iba a sanar el enfermo con éxito*
*Le pidieron que realizara el sacrificio*
*En los días antiguos*
*Ellos emplean el fuego tratando a cualquiera que está enfermo*
*Una vez cualquiera se aflige con cualquier tipo de enfermedad*
*Ellos harían un fuego para él sentarse cerca*
*La sangre se pondría calurosa*
*Cuando el cuerpo se pone caluroso*
*Ellos prescribirían otras medicinas para usar en el acompañamiento con el fuego*
*La enfermedad habría sanar*
*'Usted el Fuego, ofrezca sacrificio tal que ellos no se lo opondrían después' ellos dijeron*
*'Ofrecer sacrificios significa para detractores*
*'Yo'! El fuego dijo*
*'¿Tan grande como yo soy?'*
*'¿Qué yo necesito para cualquier sacrificio?'*
*Entretanto el agua y fuego eran enemigos jurados*
*Ellos contrataron el Agua entonces*
*Una vez se había usado el fuego para sanar el enfermo*

*Ellos usarían el agua para extinguirlo*
*Ellos reembolsaron el fuego con la ingratitud*
*El fuego estaba alabando su Babaláwo tardíamente*
*Él empezó a lamentar en la agonía entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwo*
*Su Babaláwo estaba alabando Ifá*
*Él dijo que era exactamente como el Babaláwo predijo*
*El árbol de Odán en espacio libre fuera con una sombra ancha*
*Adivinación lanzada para el Fuego*
*El que iba a sanar el enfermo con éxito*
*Le pidieron que realizara el sacrificio*
*Él debe realizar el sacrificio antes de que él embarcara en ir a tratar al enfermizo*
*Él oyó hablar todavía él no lo realizó*
*El fuego curo después al enfermizo*
*Ellos extinguieron el fuego completamente.*

***Òfún Ìrosùn A***
*Ifá pé ká rúbọ fún ọmọ kan nínú ọmọọ wa. A lè ti bí ọmọ náà tàbí kó wà lójú ọ̀nà; Ẹlẹ́gbẹ́ lomo ọ̀hún. Kí àwọn òbí ẹ̀ ó máṣe fi aṣọ osùn bò ó lárá tó bá ti sùn lálẹ́. Kókó osùn àti aṣọ osùn lẹ̀bọ ẹ̀.*

*Àsẹ̀sẹ̀ ràn Oòrùn*
*Níí faraá jàjà lára ògiri*
*A díá fún Òfún*
*Èyí tí ń lọ rèé gbé Olósùn níyàwó*
*Wọ́n ní kó rúbọ*
*Nígbà tí Òfún ó fẹ̀ẹ́ aya*
*Olósùn ló fẹ́*
*Wọ́n ní kí wọ́n ó rúbọ ọmọ*
*Wọ́n bá rúbọ*
*Olósùn ò wáá mọ̀ pé aṣọ Òsún lóùn ó wàá*
*Tí òun í fi máṣe bo àwon omo òun*
*Bílẹ̀ bá ti ṣú*
*Àwọn ọmọ ò bá jẹ́ kí wọn ó sùn*
*Wọ́n bá tọ Ọ̀rúnmìlà lọ*
*Gba àwọn dákuùn!*
*Ọ̀rúnmìlà ní kí wọ́n ó tọ́jú aṣọ Òsún*
*Kí wọ́n ó máṣe fi àwọn ọmọ lára*
*Ọ̀rúnmìlà ní gbogbo iree yín pọ̀*
*Ifá pé bí aṣọ yìí ò bá wọ́n won*
*Gbogbo ará Ilé eléyìun ò níí fẹ́ rere kù*
*Ni ọ́n bá ṣe bẹ́ẹ̀*
*Ni ọ́n ń fi aṣọ Òsún bo àwọn ọmọ lára*
*Ni ọ́n bá ń sùn*
*Iré bá ń wọ ilée wọn*
*N ni wọ́n wá ń jó ni wọ́n ń yọ̀*
*Wọ́n ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tàwọ́n wí*
*Àsẹ̀sẹ̀ ràn Oòrùn*
*Níí faraá jàjà lára ògiri*
*A díá fún Òfún*
*Èyí tí ń lọ rèé gbé Olósùn níyàwó*
*Ẹbọ ń wọ́n ní ó ṣe*
*Ó wáá gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ó rúbọ*
*Àṣé Òfún Olósùn  ló gbóge*
*Laà fi tètè sùn?*
*Laà fi tètè wo?*
*Àṣé Òfún Olósùn ló gbóge*
*A wáá gbẹ́bọ nígbà yí ò*
*A rúbọ*
*Òfún Olósùn wọn ò gbòge mó.*

***Òfún Ìrosùn A***
*Ifá quiere que nosotros ofrezcamos el sacrificio para uno de nuestros niños. El niño puede haber nacido o en camino. El él o ella es un Elégbé, un niño con los compañeros celestiales. Los padres siempre deben usar un tejido rojo para cubrirlo una vez que él está dormido más sobre todo por la noche. Las pelotas de leva de madera [camwood] y un rollo de tejido rojo son el sacrificio.*

*Como aclarar el sol frescamente*
*Chamuscaría en lado de la pared*
*Adivinación lanzada para Òfún*
*El que iba a casarse a Olósùn como una esposa*
*Le pidieron que ofreciera el sacrificio*
*Cuando Òfún vaya a una mujer se casara*
*Él se casó Olósùn*
*Ellos ambos fueron pido ofrecer el sacrificio para los niños*
*Ellos lo realizaron*
*Olósùn no supo que ella tiene que buscar una tela roja*
*Y usarla para cubrir él los niños*
*Una vez al anochecer*
*Los niños los desaprobarían de dormir*
*Ellos fueron a encontrarse Òrúnmìlà entonces*
*'Ayúdenos', ellos lloraron*
*Òrúnmìlà les pidió que prepararan una tela roja*
*Y debe usarlo para siempre cubrir a los niños en la noche*
*'Sus fortunas son bastante', dijo Òrúnmìlà*
*Ifá dice si estos niños se cubren con la tela roja*
*Toda la casa de esta persona no estaría en la carestía de fortunas*
*Ellos hicieron como ellos les dijeron*
*Ellos cubrieron a los niños con una tela roja*
*Ellos durmieron después bien*
*Las fortunas empezaron a entrar en su casa*
*Ellos empezaron a bailar y regocijar entonces*
*Ellos estaban alabando su Babaláwo*
*Su Babaláwo estaba alabando Ifá*
*Ellos dijeron que era como su Babaláwo había dicho*
*Como aclarar el sol frescamente*
*Chamuscaría en lado de la pared*
*Adivinación lanzada para Òfún*
*El que iba a casarse a Olósùn como una esposa*
*Les pidieron que ofrecieran el sacrificio*
*Ellos oyeron hablar del sacrificio*
*Y lo realizaron*
*¡Así que es Òfún Olósùn que llevó Oge!*
*Nosotros oímos hablar ahora del sacrificio*
*Y lo realizamos*
*Òfún Olósùn no lleva Oge ya.*

***Òfún Ìrosùn B***
*Bí ẹni a dáfá yìí fún bá leían lókèèrè tí wọ́n sì fẹ́ẹ́ ráńsẹ́ pè ará òkèèrè ọ̀hún ò gbọdọ̀ wá. Bí bẹ́ẹ̀ kó, ń bọ̀ wáá kú ni. Ifá pé ká ṣírò ọmọ osú tí ń bẹ nílée wa, ká sì fún ọ̀kọ̀ọ̀kan won ní ¸adìe kòọ̀kaṇ ¸kí wón ó fi rúbo.* ¸

*A fún ro*
*A fùn ro*
*Afùnrò ǹ funrò*
*Àwọn ló ṣefá fún Òkùràkùtà*
*Èyí tí ń gẹṣiín bọ̀ wálé*
*Ìṣẹ̀lẹ̀ kan ló ṣẹlẹ̀ ńlé*
*Wọ́n bá ráńṣẹ́ sí Òkùràkùtà*
*Òun náà bá kó ẹrú*
*Ó di ẹrù*
*Ń gẹṣin bọ̀ wálé*
*Bo ti dé Ilé*
*Tí ọ́n kí i káàbọ*
*Kó bọ̀ọ̀lẹ̀*
*Ló bá lulẹ̀*
*Ó bá kú*
*Wọ́n lawọn ò wí fún ìwọ¸ọmọ¸osú*
*Tóo ní dandan gbọ̀n*
*Afi kó wálé*
*Ló gẹṣin wálé wáá kú un*
*Ó ní A fún ro*
*A fùn ro*
*Afùnrò ǹ funrò*
*A díá fún Òkùràkùtà*
*Èyí tí ń gẹṣiín bọ̀ wálé*
*Òkùràkùtà tẹ́ẹ̀ ní ń gẹ́ṣin bọ̀ wálé*
*Àṣé ń gẹṣiím bò wáá kú ni*
*Òkùràkùtà*
*O gbẹ́bọ bẹ́ẹ̀ loò rúbọ*
*Òkùràkùtà*

***Òfún Ìrosùn B***
*Ifá dice que esta persona tiene una pariente en el extranjero de quien se necesitaría la atención en casa; Ifá advierte contra enviar para el extranjero la persona. Si él debe decidir regresar, él volvería para morirse. Esta persona debe dar cada uno a un pollo a todos 'Omo Osú en su compuesto (componer, mezcla) para ofrecer como el sacrificio.*

*A fún ro*
*A fùn ro*
*Afùnrò*
*N funrò*
*Adivinación lanzada para Òkùràkùtà*
*El que estaba montando un caballo a casa*
*Una incidente había pasado en casa*
*Ellos enviaron por Òkùràkùtà*
*Él condensó (empaco) a sus esclavos también*

*Y condensó todo sus efectos*
*Él montó en un caballo para devolver casa*
*Inmediatamente él llegó a casa*
*Él estaba intercambiando las bromas*
*Como él estaba ansioso a apearse el caballo*
*Él se cayó*
*Y se murió*
*'¿Nosotros no le dijimos?'*
*'Cuando todos ustedes fueron desafiantes'*
*'Diciendo no hay ninguna otra opción excepto al regresa a casa'*
*'Vea cómo él había montado a casa en un caballo morirse' ellos los recordaron*
*Ellos dijeron A fún ro*
*A fùn*
*Afùnrò n funrò*
*Adivinación lanzada para Òkùràkùtà*
*El que estaba montando a casa un caballo*
*Okurakíta que usted dijo es la próxima casa en un paseo de caballo*
*Está montando a casa un caballo realmente para morirse*
*Òkùràkùtà*
*Usted oyó hablar todavía del sacrificio no lo ofreció*
*Òkùràkùtà*

***Òfún Ọ̀wọ́nrín A***
*Eléyìun ti gbìíyànjú ajé ní gbogbo ọ̀nà. Iré ń bọ̀ ti a bá lè rú sùúrù ẹ́bọ. A kò kọ iré ajé púpọ̀ fún wa lọ́jọ́ àárọ̀, ṣùgbọ́n ká rúbọ kí ìgbà ajé náà ó tètè dé.*

*Mo sányán sányán*
*Mo fẹ́ẹ́ẹ́ kú*
*A díá fún Ọ̀rúnmìlà*
*Tí Babá ó dọlọ́bẹ̀ lọ́la*
*Wọ́n ní ko rúbọ*
*Wọ́n ní kó gún Iyán*
*Kée bọ òkè ìpọ̀rí ẹ̀*
*Kó wáá bu òkèlè méje nnú Iyán ọ̀hún láì lọ́bẹ̀*
*Kó lọ̀ọ́ fi lé ibi òkè ìpọ̀rí ẹ̀*
*Kó pé bóun tíí jẹ́ ẹ́ nùu lái lọ́bẹ̀*
*Dandan ni kíre òún ó dé*
*Wọ́n ní àyípadà ó ba*
*Ọ̀rúnmìlà ṣe bẹ́ẹ̀*
*Gbogbo nǹkan bá yí padà sí rere*
*Ní bá ń jó ní ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Mo sányán sányán*
*Mo fẹ́ẹ́ẹ́ kú*
*A díá fún Ọ̀rúnmìlà*
*Tí Babá ó dọlọ́bẹ̀ lọ́la*
*Ẹbọ n wọ́n ní kí Babá ó ṣe*
*Ọ̀rúnmìlà gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ó rúbọ*
*Ó tí ń sányán sányán bíi fẹ́ẹ́ẹ́ kú o*
*Ìgbẹ̀yìn*
*Babá wáá dọlọ́bẹ̀ o*
*Ìgbẹ̀yìn*

***Òfún Òwónrín A***
*Ifá dice que esta persona tendría la fortuna tarde (retrasada, tardía) en la vida. No importa el esfuerzo que él pone en su trabajo presente, él no tendría éxito, sería pronto bien pero debe ofrecer sacrificio tal que no sería demasiado largo (extenso, prolongado).*

*Yo comí rondas de ñame machacado sin el estofado (guiso)*
*Yo me morí casi*
*Adivinación para Òrúnmìlà*
*Baba tendrían el estofado pronto para comer pronto*
*Le pidieron que realizara sacrificio*
*Le pidieron que preparara el ñame machacado*
*Y lo usa como sacrificio a su Ifá*
*Él debe recortar entonces fuera siete trozos de ñame machacado sin el estofado*
*Él debe ponerlo encima de su Ifá*
*'Eso es cómo yo lo como sin el estofado' él debe decir así a su Ifá*

*'Es indispensable que sus fortunas vienen a usted', ellos habían dicho*
*'Debe haber un cambio', ellos le aseguraron*
*Òrúnmìlà hizo como lo instruyeron*
*Todas sus cosas cambiaron para bien*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwo*
*Su Babaláwo estaba alabando Ifá*
*Él dijo que era como su Babaláwo había dicho*
*Yo comí y comí rondas de ñame machacado sin el estofado*
*Yo me morí casi*
*Adivinación lanzada para Òrúnmìlà*
*Baba tendrían el estofado pronto a la oreja*
*Le pidieron que realizara el sacrificio*
*Òrúnmìlà oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó*
*Él había estado comiendo ñame machacado seco continuamente como si él estuviera haciendo para morir*
*Por fin*
*Baba tiene el estofado ahora*
*Por fin*

***Òfún Ọ̀wọ́nrín B***
*Ifá pé eléyìun ó kọ̀ọ́ Ilé, yóó tùún yọ káà ńbẹ̀. Gbogbo àwọn ọmọ̀ ti eléyìun bí ní ó kọ̀ọ́̀ Ílé nlá láyé.*

*Iṣú jinná*
*Ọmọ odó wẹ̀rí*
*Ọbẹ̀ jinná*
*Mọ́ dábọ̀ọ kọ̀tọ̀ kọ̀tọ̀ ń sísọ̀ kalẹ̀*
*Iyán tí ò lọ́bẹ̀ abara gírísasa gírísasa*
*A díá fún Òfún*
*Èyí tí ò pọn Ọ̀wọ̀n ká innúu káà*
*'Èèyàn kún inú Ilé òun báyìí'?*
*Ayé yẹ̀ọun?*
*Ọkán òun balẹ̀?*
*Wọ́n ní kó rúbọ*
*Wọ́n lọ́mọ odó kan àti ìyá odó kan lẹ̀bọ ẹ̀*
*Wọ́n ní àpọ̀lọ̀pọ̀ isu lẹ̀bọ ẹ̀*
*Wọ́n ní kó gún Iyán kèè bòkè ìpọ̀rí ẹ̀*
*Kó wáá sẹ̀jẹ kó semu*
*Ó sẹ bẹ́ẹ̀*
*Wọ́n ní ko tọ́jú ewúré̀ kèè bọ̀ Ifá*
*Ó tọ́jú ewúré̀*
*Ó fi bọ̀ Ifá*
*Gbogbo èèyán bá ń yọ̀ nlé ẹ̀*
*Ni ọ́n ń jẹun*
*Ló bá bẹ̀rẹ̀ síí kọ́lé*
*Ariwo búrúkú ò sẹ̀lẹ̀ ńlẹ́ ẹ̀ mọ́*
*Ariwo iré ní ń rí*

*Ariwo owó*
*Aya*
*Ọmọ*
*Ẹ̀míi rẹ̀ gùn*
*Ó gbó, ó tọ́*
*Ayé yẹ́*
*Ní bá ń yin àwọn 'Iṣ́ú jinná ọmọ odó wẹ́rí'*
*Àwọn Obẹ̀ jinná mọ́ dábọ̀ọ̀ kọ̀tọ̀ kọ̀tọ̀ ń sísọ̀*
*Àwọn Iyán ti ò lọ́bẹ̀ abara gírísa gírísasa*
*Àwọn Babaláwo náà ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Iṣ́ú jinná*
*Ọmọ odó werí*
*Ọbẹ̀ jinná*
*Mọ́ dábọ̀ọ̀ kọ̀tọ̀ kọ̀tọ̀ ń sísọ̀*
*Iyán tí ò lọ́bẹ̀ abara gírísasa gírísasa*
*A díá fún Òfún*
*Èyí tí ó pọn Ọ̀wọ̀n ká inúu káà*
*Òfún ló pon Ọ̀wọ̀n ká inúu káà*
*Ariwo ajé hèè*
*Ariwo aya hèè*
*Ariwo ọmọ hèè*

***Òfún Ọ̀wọ́nrín B***
*Ifá dicen que esta persona construiría casas y cuartos separados. Los niños harían lo mismo también.*

*El ñame se cocina*
*La cabeza de la mano de mortero se lava*
*El estofado se hace*
*No hace debido al burbujeo que se niega a llevárselo fuera del fuego*
*El ñame machacado sin el estofado con el cuerpo tosco*
*Adivinación del lanzamiento para Òfún*
*Que ataría Òwòn a su espalda en el salón de descanso*
*'¿Habría muchas personas en mi casa?'*
*'¿La vida me agradaría?'*
*'¿Y tiene descanso de mente?'*
*Le pidieron que realizara el sacrificio*
*Un mortero y una mano de mortero es el objeto de sacrificio*
*Muchos tubérculos de ñame son el sacrificio*
*Machacado también debe ofrecerse a Ifá*
*Él debe preparar comida y bebidas entonces para las personas*
*Él hizo como lo instruyeron*
*Le pidieron después que preparara una cabra para sacrificar a Ifá*
*Él preparó la cabra*
*Él lo sacrificó a su Ifá*
*Todas las personas empezaron alegrar en su casa*
*Ellos estaban comiendo*
*Él empezó a construir las casas después*
*Ningún lamento doloroso o agónico se oyó en su casa*

*Él oyó sólo el aclamo de noticias buenas*
*El aclamo de dinero*
*Esposas*
*Niños*
*Él tenía la vida larga*
*Él se envejeció y firme (inmóvil, constante) a la vejez*
*La vida lo agrada así*
*Él empezó la alabanza entonces al sacerdote 'Isú jinná omo odó werí'*
*El sacerdote 'Obè jinná mó dábòo kòtò kòtò n síso'*
*El sacerdote 'Iyán tí ò lobe abara gírísasa gírísasa'*
*Los Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que es como su Babaláwos dijo*
*El ñame se cocina*
*La cabeza de la mano de mortero se lava*
*El estofado se hace*
*No hace debido al burbujeo que se niega a llevárselo fuera del fuego*
*El ñame machacado sin el estofado con el cuerpo tosco*
*Adivinación lanzada para Òfún*
*El que llevaría Òwòn en su espalda en el salón de descanso*
*Es Òfún que llevó Òwòn en el salón de descanso*
*El ruido sobre la riqueza en un aclamo*
*El ruido sobre las esposas en un aclamo*
*El ruido sobre los niños en un aclamo*

***Òfún Ọ̀bàrà A***
*Ifá pé ìre lọ́pọ̀lọpọ̀ ti a bá ń ta Ìbejì lọ́ṛẹ*

*Páńsá ojúbuná abara dúdú ẹẹ̀te ẹẹ̀te*
*A díá fún Ẹ̀yẹ̀lé*
*Nijọ́ tí ń tọ̀run bọ̀ wálé ayé*
*Ti ń fomi ojú sògbérè ọmọ̀*
*Wọ́n ní ó rúbọ*
*Ẹ̀yẹ̀lé bá rúbọ*
*Wọ́n ní méjí méjí lẸ̀yẹ̀lé ó móọ̀ bí*
*Ó bá bẹ̀rẹ̀ síí bímọ*
*Ilé bá kún*
*Ọmọ Eyẹ̀lẹ́ pọ̀*
*Ní bá ń jó ní ń yò*
*Ní ń yin Ifá*
*Ifá ń yin Olódùmarè ọba*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Pánsá ojúbuná abara dúdú ẹẹ̀te ẹẹ̀te*
*A díá fún Ẹ̀yẹ̀lé*
*Nijọ́ tí ń tọ̀run bọ̀ wálé ayé*
*Ti ń fomi ojú sògbérè ọmọ̀*
*Ẹbọ ń wọn ní ó ṣe*
*Ẹ̀yẹ̀lé gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ó rúbọ*
*Rírú ẹbọ*
*Èèrù àtùkèṣù*
*Ẹ wáá báni ní jẹ̀bútú ọmọ̀*
*Jẹ̀bútú ọmọ̀ làá báni lẹ́ṣẹ̀ ọba Òrìṣà*

***Òfún Ọ̀bàrà A***
*Ifá desea bien a esta persona. Él debe dar regalos para bebes gemelos. La vida estaría bien con él.*

*La olla en el fuego encendido con cuerpo muy negro*
*Adivinación lanzada para la Paloma*
*En el día ella estaba viniendo del cielo a la tierra*
*Ella estaba llorando debido a los niños*
*Ellos le pidieron que realizara sacrificio*
*La Paloma realizó el sacrificio*
*Ellos le dijeron que ella tendría gemelos*
*Ella empezó teniendo niños*
*La tierra entera estaba llena*
*Sus niños eran muchos*
*Ella estaba bailando y estaba regocijando*
*Ella estaba alabando Ifá*
*Ifá estaba alabando Olódùmarè el Omnipotente*
*Ella dijo que era como su Babaláwo dijo*
*La olla en el fuego encendido con cuerpo muy negro*
*Adivinación lanzada para la Paloma*
*La Paloma estaba viniendo del cielo a la tierra*

*Ella estaba llorando debido a los bebés*
*Era el sacrificio que pavimentaría el camino para ella tener niños que se recomendaron para ella*
*La Paloma oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó*
*Ofreciendo sacrificios*
*Y regalos libres a Èsù*
*Venga y encuéntresenos con la fortuna buena de niños*
*Uno normalmente se encuentra con la fortuna buena de niños a los pies del rey de Òrìsà*

***Òfún Ọ̀bàrà B***
*A à níí rẹ́bù ẹ̀yìn. Ifá pá ká rúbọ fún àmì ọmọ kan tí ń bọ̀ ká sì rúbọ àmì èèyàn ó mọ́ lọ. Àárẹ̀ ò níí ṣe wá; a ò sì níí kú lójijó àìpé tí a bá rúbọ odù yí.*

*Pápá ló jó ló mọ́ tanhún tanhún*
*Ògúnná kan ṣoṣooṣo ló sọ ẹ̀lùjù dilẹ̀ẹ́lẹ̀*
*A díá fún Ànrèré omo Olódùmarè*
*Ọmọ atẹ́ní lẹ́gẹ́lẹ́gẹ́ forí sagbeji omi*
*Wọ́n ní ó rúbọ*
*Ó bá rúbọ*
*Wọ́n ṣe Ifá fún Ànrèré*
*Wọ́n ní ayé dùn*
*Mọ́ lọ*
*Ànrèré ò bá kú mọ́*
*N ní bá ń jó ní ń yọ̀*
*Ni ń yin  àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Pápá ló jó ló mọ́ tanhún tanhún*
*Ògúnná kan ṣoṣooṣo ló sọ ẹ̀lùjù dilẹ̀ẹ́lẹ̀*
*A díá fún Ànrèré omo Olódùmarè*
*Ọmọ atẹ́ní lẹ́gẹ́lẹ́gẹ́ forí sagbeji omi*
*Nijọ́ ti ọ́n ní ó rúbọ sáìkú araa rẹ*
*Ayé dùn mọ́ lọ*
*Ànrèré ò ayé dùn mọ́ lọ*
*Ayé mọ̀mọ̀ dùn*
*Ànrèré ayé dùn*
*Mọ́ lọ*

***Òfún Ọ̀bàrà B***
*Ifá dice que nosotros no veríamos guerra en nuestras vidas. Esta persona debe realizar sacrificio, pendiente la llegada de un niño de substancias (esencia); y recíprocamente para que una persona de substancias no se muriera prematuramente. Él disfrutaría su vida completa.*

*Cuando los campos queman, aclara la tierra*
*Sólo un carbón de leña ardiente reduciría el bosque grande para aclarar tierra*
*Adivinación lanzada para Ànrèré el niño de Olódùmarè*
*El niño de 'Atení légélégé forí sagbeji omi '*

*Le pidieron que realizara sacrificio*
*Él lo realizó*
*Ellos prepararon una porción de Ifá para Ànrèré*
*La vida es dulce*
*No vaya, ellos le dijeron*
*Ànrèré se negó a morirse de nuevo*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando sus Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que es como sus Babaláwos dijeron*
*Cuando los campos queman, aclaran la tierra*
*Sólo un carbón de leña ardiente reduciría el bosque grande a un piso y aclara la tierra*
*Adivinación lanzada para Ànrèré el niño de Olódùmarè*
*El niño de ' Aténí légélégé forí sagbeji omi '*
*En el día que ellos le pidieron realizar sacrificio para fortificarlo contra la muerte*
*La vida es dulce, no vaya*
*Ànrèré*
*La vida es dulce*
*Ànrèré, la vida es muy dulce*
*No vaya.*

***Òfún Ọ̀kànràn A***
*Ifá pé rúbọ ọmọ. Aà níí réèmọ̀ọ kín nìí. A o si gbọ́dọ̀ Sahún o; Nǹkankan ń be,ti àwọn eléyìun ò mọ ojútùú rẹ̀. Ifá pé kí wọ́n ó to àwọn àgbàlagbà lọ, wọ́n ó rídìí ẹ̀.*

*Agogo ní ń ró ẹ pé péré*
*Àràn gẹ̀jẹ̀ ní ń ró mọ̀ kọ́mọ jọ mọ̀ kọ́mọ,jọ*
*A díá fún Kóórì*
*Èyí ti ń fomi ojúu sògbérè ọmọ*
*Òun le rọ́mọ bí báyìí?*
*Wọ́n ní ó rúbọ*
*Wọ́n ní àgbédọ̀ adiẹ lẹ́bọ*
*Ló bá pa adìẹ fúnra ẹ̀*
*Ńbẹ̀ náà ló ti sè e*
*Ńbẹ̀ náà ló ti jẹ ẹ́*
*Kò rọ́mọ kankan bí*
*Ó tún dẹ̀ẹ̀kejì*
*Ó tún pa adìẹ*
*Ó tún dá a jẹ*
*Kò rọ́mọ pîìn*
*Nígbà ó dẹ̀ẹ̀kẹ́ta*
*Ó bá lọ̀ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà*
*Họ́wù!*
*Wọ́n ní kóun ó fi àgbébọ adìẹ rúbọ lẹ́ẹ̀kíní*
*Òún fi rúbọ lẹ́ẹ̀kejì*
*Wọ́n sì ní àwọn ọmọ ń tẹ̀lé òun kíri*
*Ọ̀rúnmìlà níwọ Kóórì loò ṣeun*
*Ò ń pa adìẹ*
*O sì ń dá a jẹ*
*Ọ̀rúnmìlà ní kí Kóórì ó lọ́ọ̀ fi ìdodo kan ògiri*
*Lẹ́nu ibi ti ìdodo ẹ̀ bá ga mọ lára ògiri*
*Kó sàmì síbẹ̀*
*Kó wáá pa adìẹ mìíìn*
*Kó mú ẹ̀jẹ̀ adìẹ ọ̀hún*
*Kó fi yí ojú àmí ọ̀hun*
*Kí ẹ̀jẹ̀ adìẹ ó wáá sàn wálẹ̀*
*Kó sì ta epo díẹ̀ sí ojú ibẹ̀ náà*
*Ọ̀rúnmìlà ni kó mọ́ jẹ ńbi adìẹ*
*Ọ̀rúnmìlà ní tí ò bá ti jẹ ńbẹ̀*
*Àwọn ọmọ ó tẹ̀le*
*Kóórì bá ṣe bẹ́ẹ̀*
*Ó bá kó gbogbo àwọn èèyàn jọ*
*Kò jẹ̀ ńnú è*
*Ọmọ́ bá dé*
*Kóórì bímọ yè*
*Ní bá ń jó ní ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo n yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Agogo ní ń ró ẹ pé pére*
*Àràn gẹ̀jẹ̀ ní ń ró mọ̀ kọ́mọ jo mọ̀ kọ́mọ,jọ*

*A díá fún Kòòrì*
*Èyí ti n fomi ojúú sògbérè ọmọ*
*Tí sì ń rodò ti ò rọ́mọ kó wálé*
*Ó lọ nígbà èèkínní*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò rọmọ mú wálé*
*Ó lọ nígbà èèkejì*
*Kò rọ́mọ mú wálé*
*Ni ọ́n bá ń kọrin fún Kóórì*
*Wọ́n ń pé bí ó lọ*
*Kó mọ́ọ lọ*
*Ẹ jẹ́ Kóórì ó rodò*
*Bí ó lọ kó mọ́ọ lọ*
*Ó japá*
*Ó jẹtan*
*Ó jẹ̀dí*
*Ó jẹ̀dọ̀*
*Bí ó lọ kó mọ́ọ lọ*
*Wọ́n ní bí ti ń padìẹ ní ń dá jẹ ẹ́*
*Ìgbà èèkẹta lỌ̀rúnmìlà ṣe Ifá fún Kóórì*
*Ó ní Kóórì o*
*Ó mọ̀ dé aréwe yọ̀*
*Fún mi lọ́mọ kan n gbé jó*

***Òfún Ọ̀kànràn A***
*Ifá le pide a esta persona que ofrezca sacrificio de niños. Él no debe ser avariento (avaro, tacaño). Hay un enigma particular que la familia de esta persona o los amigos no saben la solución. Ellos deben acercarse a los superiores.*

*Congréguense ustedes mismos es el sonido del gong*
*Àràn gèjè parece que yo reuniré a los niños*
*Adivinación lanzada para Kóórì*
*Un llanto debido a los niños*
*Habría yo tener os niños es la pregunta que ella le hizo a Ifá*
*Ellos le dijeron que realizara sacrificio*
*Una gallina madura es el sacrificio*
*Ella mató la gallina de ella*
*En la sitio dónde ella le cocinó*
*Estaba en la mismo sitio que ella lo comió*
*Ella no obtuvo ningún niño*
*Ella vino, mientras llamaba la segunda vez*
*Ella mató otra gallina madura*
*Ella comió la gallina sola*
*Ella no encontró a ningún bebé*
*Después de esto ningún en la tercera ocasión*
*Ella fue a consultar Òrúnmìlà*
*'Por qué tiene estos infortunios ser mi nube (nublar)'? Ella preguntó*
*'Ellos me dijeron a mí sacrificar una gallina madura cada uno en dos ocasiones anteriores*
*'Yo lo ofrecí'*
*'Y ellos me dijeron que los niños están siguiéndome alrededor', Kóórì dijo'*

*'Usted es el que no siguió las instrucciones dado a usted' Òrúnmìlà contestó*
*'Usted mató todos los animales asignados para usted'*
*'Usted lo comió sola'*
*Òrúnmìlà le dijo entonces a Kóórì que usara su ombligo para tocar una pared derecha (erguida, vertical)*
*La altura a que el ombligo alcanza en la pared*
*'Usted debe marcar esa sitio'*
*Usted debe matar otra gallina entonces'*
*'Coleccione su sangre alrededor de esto*
*'Y lo usa para untar el sitio de la marca del ombligo*
*'Tal que la sangre gotearía abajo a través del rastro de la marca'*
*Usted también debe untar un poco de aceite rojo de palma en la mismo sitio*
*Usted nunca debe comer fuera el pollo, Òrúnmìlà dijo*
*Una vez que usted no come fuera del pollo*
*Los niños vendrían a usted*
*Kóórì hizo como la instruyeron*
*Ella congregó a las personas*
*Ella no saboreó fuera del pollo*
*Los bebés empezaron a venir entonces*
*Ella tenía el parto exitoso*
*Ella empezó a bailar y regocijar entonces*
*Ella empezó a bailar y regocijar entonces*
*Ella estaba alabando sus Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Ella dijo que era como sus Babaláwos habían dicho*
*Congréguense ustedes mismos en la totalidad es el sonido del gong*
*Àràn gèjè parece que yo recogeré a los niños*
*Adivinación lanzada para Kóórì*
*Un grito debido a los niños*
*Una ida al arroyo sin el agua atractiva con ellos*
*Ella intentó la primera vez*
*Todavía no podría encontrar a un bebé para traer a casa*
*Ella fue la segundo vez*
*Ella no podría traer un niño a casa*
*Ellos empezaron a cantar burlándose de ella entonces*
*Si ella quiere ir*
*Permítale ir*
*Permítale ir al arroyo*
*Si ella quiere ir, permítale ir*
*Ella comió las alas exclusivamente*
*Ella comió suave (rejazo, falda)*
*Ella comió las nalgas*
*Ella comió el hígado*
*Permítala ir si ella quiere ir que ellos dijeron que estaba en la mismo sitio dónde ella mató la gallina que ella lo devoró*
*Estaba en la tercera ocasión que Òrúnmìlà preparó una porción de Ifá para Kóórì*
*Kóórì, ellos la aclamaron*
*El que regocija a la vista del regreso de los niños*
*Por favor déme un abrazo.*

***Òfún Ọ̀kànràn B***
*Ti a bá ní gbólóhùn asọ̀ pẹ̀lú ẹnìkan tó sún mọ́ wa pẹ́típẹ́tí; Ifá gbà wá níyànjú Kà parí ẹ̀ torí àṭẹnìkínní àṭẹnìkejì ló ní àwíjàre. Tì a bá ḳò ti a kò tún àárin ọ̀n se ` nnkan ṭi ó bą́jè ó pò.*

*Agogo ní ń ró ẹ pé péré*
*Àràn gèjè ní ń ró mọ̀ kọ́mọ jọ; mọ̀ kọ́mọ jọ*
*Mọ̀ kọ́mọ jọ́ nìyá àràn ń ró*
*A díá fún Òfún*
*A bù fún Ọ̀lọ̀kànràn*
*Níjọ́ọ wọ́n ń sọta*
*Wọ́n ń fi ìbínú bá araa wọn lò*
*Wọ́n ṣe ṣee ṣe*
*Wọn ò gbọ́*
*Àwọn ni ọ́n sì ń ṣe Ifá fún Olúufẹ̀*
*Wọ́n ní ẹ bẹ Òfún*
*Kẹ́ẹ sì bẹ Ọlọ̀kànràn*
*Bí bẹ́ẹ̀ kọ́*
*Nǹkan Olúufẹ̀ ó bájẹ̀*
*Wọ́n bá bẹ Òfún*
*Wọ́n bẹ Ọlọ̀kànràn*
*Ayé Olúufẹ̀ bá tutu*
*N ni wọ́n wá ń jó n ni wọ́n ń yọ̀*
*Ni wọ́n ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Wọ́n ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tàwọ́n wí*
*Agogo ní ń ró e pẹ́ péré*
*Àràn gẹ̀jẹ̀ ní ń ró mọ̀ kọ́mọ jọ; mọ̀ kọ́mọ jọ*
*Mọ̀ kọ́mọ jọ nìyá àárán ń ró*
*A día fún Òfún*
*A bù fún Ọlọ̀kànràn*
*Nijọ́ọ wọ́n ń sọta*
*Ẹ jẹ́ á bẹ Òfún*
*Ẹ jẹ́ á bẹ Ọlọ̀kànràn*
*Káyé Olúufẹ̀ ó lè tutù*
*Káyé Oluufẹ̀ ó lè rójú*

***Òfún Ọ̀kànràn B***
*Esta persona tiene un feudo incierto entre él y una otra persona. Ellos dos deben encontrar una solución amigable, como los dos se vindicarían por su propio lado de sus explicaciones. El feudo debe establecerse; por otra parte sembraría muchas semillas de discordia.*

*Congréguense ustedes mismos es el sonido del gong*
*Àràn gèjè suena 'yo recogeré a los niños'*
*Yo congregaría a los niños es el sonido producido por la madre del tambor de Àràn*
*Adivinación lanzada para Òfún*
*También adivinación lanzada para Olòkànràn*
*En el día ellos dos guardaron una malicia mala entre ellos*
*En el día que ellos estaban en nosotras gargantas*

*Las personas intentaron e intentaron hacerles enterrar el hacha*
*Ellos se negaron a escuchar*
*Pero ellos son unos que realizan adivinación para Olúufè*
*'Permítanos pedir Òfún*
*'Permítanos también pacificar Olòkànràn'*
*'Por otra parte'*
*La vida de Olúufè se estableció*
*Ellos empezaron a bailar y regocijar entonces*
*Ellos estaban alabando sus Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Ellos dijeron que era como sus Babaláwos habían dicho*
*Congréguense ustedes mismos es el sonido del gong*
*Àràn gèjè suena 'yo recogeré a los niños'*
*En el día que ellos dos guardaron la malicia mala entre ellos*
*Permítanos pedir Òfún*
*Permítanos pedir Olòkànràn*
*Tal que cosas de Olúufè se establecerían*
*Tal que la vida de Olúufè haría el avance (progreso)*

***Òfún Ògúndá A***
*Ifá wúré fún ẹní ó dáfá yìí pupọ. Bí ẹnìkán bá ṣoore fún un, kó gbọdọ̀ fibi ṣú onítọ̀hún. Bí wọn ò bá sì bá sì tîì ṣoore fún un, iré n bọ̀ láìpẹ́.*

*Òfún i dùn*
*Òsùnsùn i dùn*
*A díá fún Ògún*
*Èyí tí ó rọ Ẹdùn fún Sàngó*
*Ògún ni Sàngó jà tẹ́lẹ̀*
*Àtiwájú àtẹ̀yìn níí fíí jagun*
*Irúu kínlòun ó wáà mọ́ọ fi jagun*
*Tí ẹnìkan ò níí lè kápá òun lái?*
*Ògún ní kó fọkàn balẹ̀*
*Ó lóun ó rọ nǹkankan fún un*
*Irú àṣẹ tí ó wá lára ẹ̀*
*Kò níí sí lára ẹlọ́mîîn*
*Ló bá rọ Ẹdùn fún Sàngó*
*Sàngó dé Ògún tí ń lọ*
*Gbogbo ibi ó bá ṣo Ẹdùn sí*
*Gbogbo ẹ̀ ló dilẹ̀ẹ́lẹ̀*
*Wọ́n ní ó mọ́ gbàgbé Ògún o*
*Ni Sàngó ò bá gbàgbé Ògún*
*Tée dòní*
*N ní wá ń jó ní wá ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòón wí*
*Òfún i dùn*
*Òsùnsùn i dùn*
*A díá fún Ògún*
*Èyí ti ó rọ Ẹdùn fún Sàngó*
*Ajírẹdùn Awo rere ni*
*Ògún ló rọ Ẹdùn fún Sàngó*
*Ajírẹdùn Awo rere ni*

***Òfún Ògúndá A***
*Ifá ora para esta persona. Si él ayuda o alguien le ayuda a lograr algo, cualquier partida (parte) no debe rembolsar bien por  mal. Si la ayuda no se ha dado, una ayuda significante está viniendo en camino.*

*Òfún i dùn*
*Òsùnsùn i dùn*
*Adivinación lanzada para Ògún*
*El que amoldaría Edùn para Sàngó*
*Sàngó usó para ser un guerrero originalmente*
*Él había sido alguna vez un guerrero muy poderoso*
*'¿Qué yo usaría ahora como el instrumento de guerra?'*
*'El instrumento que nadie podría predominar (dominar, subyugar)'? Él pensó*
*Ògún le pidió que fuera descansar confiado*
*Que él, Ògún amoldarían algo de importancia para él*

*La autoridad detrás de él*
*Nunca se compararía con algo en la tierra*
*Ògún entonces lanzo Edùn para Sàngó*
*Sàngó fue a guerrear después*
*Todos los lugares a dónde él tiró su Edùn*
*Todos se volvieron un terraplén llana*
*'Pero no se olvide de Ògún ellos le dijeron*
*Sàngó desde entonces sostiene Ògún en estima alta*
*Hasta la fecha*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que era como su Babaláwos predijo*
*Òfún i dùn*
*Òsùnsùn i dùn*
*Adivinación lanzada para Ògún*
*El que amoldaría Edùn para Sàngó*
*Ajíredùn es un sacerdote bueno*
*Era Ògún que amolda Edùn para Sàngó*
*Ajíredùn es un sacerdote bueno*

***Òfún Ògúndá B***
*Ifá pé eléyìun ò gbọdọ̀ gba obì jẹ lọ́wọ́ èèyàn o; bí ọ́n bá sì pa ẹran màlúù tábì ẹran ewúrẹ́, kò gbọdọ̀ jẹ ètè ẹran. Ifá pé bí eléyìun bá rúbọ dáadáa, ojú ọ̀nà ni ọ̀táa rè ó kùú sí.*

*Ewúrẹ́ ilé yìí*
*Kèè tîì dé*
*Àgùtàn ilé yìí*
*Kèè tîì dé*
*Àwọn ìkà ènìyán pète pèrò*
*Wọ́n láwọn ó gbóbì fún Babaláwo pé kó le róhun mú jẹ*
*Wọ́n ní kó rúbọ*
*Babaláwo bá rúbọ*
*Bí ọ́n bá pé àwọ́n ó fùún Babaláwo lóbì jẹ*
*Araa wọn ni wọ́n ń báá jà*
*Wọn ò leè fún Babaláwo lóbì jẹ́ mọ́*
*Gbogbo èrò burúkú ti wọ́n ń rò lé e lórí*
*Asán ló já sí*
*Ó ní bẹ̀ẹ́ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Ewúrẹ́ ilé yìí*
*Kèè tîì dé*
*Àgùtàn ilé  yìí*
*Kèè ttîì dé*
*Àwọn ìkà ènìyán pète pèrò*
*Wọ́n láwọn ó gbodì fún Babaláwo pé kó le róhun mú jẹ*
*Wọ́n ní kí Babaláwo ó rúbọ*
*Awó gbẹ́bọ ńbè*
*Ó rúbọ*
*Ọwọ́ tewée 'má mu lọ mí'*

*Ọwọ́ tewée róro*
*Àlọ̀rìn lekòlóó fẹnuú lọlẹ̀*

***Òfún Ògúndá B***
*Ifá advierte a esta persona nunca aceptar kola para comer de alguien. Si un animal se mata, él no debe comer los labios; si él ofrece bien su sacrificio, su enemigo se moriría en el tránsito.*

*La cabra en esta casa*
*No regresa todavía*
*La oveja en esta casa*
*Ella no ha vuelto*
*Las personas malas se confabularon juntas*
*Ellos conspiraron para dar kola venenoso a un Babaláwo para que él encontrara algo que comer*
*Le pidieron que realizara sacrificio*
*El Babaláwo realizó el sacrificio*
*Cuando ellos idearon planes para darle kola*
*Ellos discreparon con ellos*
*Ellos no pudieron ningún alcance un acuerdo para dar el kola al Babaláwo*
*Todos los pensamientos malos que ellos formaron en el Babaláwo*
*Vino a cero*
*Él dijo que era como su Babaláwo dijo*
*La cabra en esta casa*
*No regresa todavía*
*La oveja en esta casa*
*Ella no ha vuelto*
*Las personas malas se confabularon juntas*
*Ellos dijeron que ellos darían el kola a un Babaláwo para que él encontrara para comer*
*Le pidieron que realizara sacrificio*
*Babaláwo oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realizó*

*Yo he obtenido la hoja de 'Má mu lò mí'*
*Yo he obtenido la hoja de 'ròro'*
*Continuamente en sus huellas, los gusanos frotarían sus bocas en la tierra*

***Òfún Òsá A***
*Ifá pé ká mọ́ọ ta Òòsà fúnfún lọ́re. Bí a bá ń bẹ lẹ́nu ìkọ́sẹ́, a ò gbọdọ̀ fi agídí fún ara ẹni ní ìyọ̀ọ̀da. A ò sì gbọdọ̀ kánjú.*

*Òfún sà á lẹ́fun*
*Òfún sà á lÓsùn*
*Òfún sà á ní mọ̀rìwò ọ̀pẹ̀ yẹ̀ yẹ̀ẹ́ yẹ*
*A díá fún Alágẹmọ tẹ́ẹ́rẹ́*
*Èyí tíí ṣe wọlé wọ̀de Òrìṣà*
*Wọlé wọ̀de Òrìṣà ni Alágẹmo*
*Nígbà ó dijọ́ kan*
*Alágẹmọ bá rò ó*
*Ó bá sá kúò lọ́dọ̀ Òòsà*
*'Òòsà ẹni ọ̀dọ̀ọ̀ rẹ́ ńkọ'?*
*Ó lóun ò ri mọ́*
*Òun ò sì tíì fún láṣẹ*
*Nbi Alágẹmọ́ lọ*
*Ó ṣe ṣee ṣe*
*Kò ba mu*
*Wọ́n lóó tùún padà lọ ọ̀dọ̀ Òòsà tóo ti kúò*
*Ó bá padà ṣọ́dọ̀ Òòsà*
*Òòsà níwọ Alágẹmọ*
*O ò níí kú*
*O ò níí rùn*
*Ẹ̀mîì rẹ ó gùn*
*Ṣùgbọ́n mọ́ọ rọra ṣe*
*Alágẹmọ bá rọra ń tẹlẹ̀ gélẹ́*
*Ayé yẹ é*
*O ni Òfún sà á lẹ́fun*
*Òfún sà á lÓsùn*
*Òfún sà á ní mọ̀rìwò ọ̀pẹ̀ yẹ̀ yẹ̀ẹ́ yẹ*
*A díá fún Alágẹmọ tẹ́ẹ́rẹ́*
*Èyí tíí ṣe wọlé wọ̀de Òrìṣà*
*Rírú ẹbọ*
*Èèrù àtùkèṣù*
*Ayé wáá yẹ wá tùtúru*

***Òfún Òsá A***
*Ifá dice que la vida agradaría a esta persona. Él debe ser generoso a los devotos de Òòsàálá. Si él todavía está entrenando y él está pensando en retroceder, él debe desistir del pensamiento.*

*Òfún marcado con tiza*
*Òfún marcado con crema de Osùn*
*Òfún decorado brillantemente con hojas de palma*
*Adivinación lanzada para Alágemo-tééré*
*El socio íntimo de Òòsà*
*Alágemo era un socio íntimo de Òòsà*
*Un día*
*Alágemo ideó un plan hábilmente*

*Él huyó de Òòsà*
*' Que sobre la persona con usted ' las Personas habían preguntado*
*' Yo no podría verlo de nuevo vino la contestación de Òòsà '*
*' A propósito yo no le he dado su libertad '*
*El lugar donde Alágemo corrió*
*Él intentó y probó sus manos*
*Él no podría encontrar rumbo de cabeza*
*' Usted tiene que remontarse a Òòsà que usted salió ', ellos dijeron*
*Él regresó entonces a Òòsà*
*' Usted Alágemo ', Òòsà dijo*
*' Usted no se morirá '*
*' Usted no se caerá enfermo '*
*' Usted vivirá mucho tiempo '*
*' Pero practique paciencia '*
*Alágemo empezó a caminar suavemente entonces*
*La vida agrado a Agemo*
*Él dijo que Òfún lo marcaría con tiza*
*Òfún lo marcaría con crema de Osùn*
*Òfún lo decoraría brillantemente con hojas de palma*
*Adivinación lanzada para Alágemo téeré*
*El socio íntimo de Òòsà*
*Ofreciendo de sacrificios*
*Y regalos libres a Èsù*
*La vida nos agrada abundantemente*

***Òfún Òsá B***
*Ifá pé kí eléyìun ó rúbọ fún àkónkótán ajé.*

*Òfún sà á, sà á*
*Ó sà á bẹ́ẹ̀ ni ò tán mọ́*
*A díá fún Òrúnmìlà*
*Babá ń sunkún òun ò lajé*
*Wọ́n lẹ́bọ ajé ni kí Babá ó ṣe*
*Òrúnmìlà bá rúbọ*
*Ajé bá ṣẹ́*
*Òfún bá bẹ̀rẹ̀ sí sà á*
*Ó sà á bẹ́ẹ̀ ni ò tán*
*N ní wá ń jó ní ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Òfún sà á, sà á*
*Ó sà á bẹ́ẹ̀ ni ò tán mọ́*
*A díá fún Òrúnmìlà*
*Babá ń sunkún òun ò lajé*
*Wọ́n lẹ́bọ ajé ni kí Babá ó ṣe*
*Ó mọ̀mọ̀ sà á, sà á o*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò tán*
*Ifá ló lajé bẹẹrẹ*

***Òfún Ọ̀sá B***
*Ifá le piden a esta persona que ofrezca sacrificio para mucho tiempo de riqueza duradera. La vida lo agradaría.*

*Òfún escogió y lo escogió*
*Él lo escogió continuamente todavía que no estaba exhausto*
*Adivinación lanzada para Òrúnmìlà*
*Baba estaba llorando que él no endureció riqueza*
*Ellos le pidieron a Baba que realizara sacrificio*
*Òrúnmìlà ofreció sacrificio entonces*
*El dinero salió entonces de la tierra*
*Òfún empezó escogiéndolo*
*Él escogió y escogió todavía que no estaba exhausto*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwo*
*Su Babaláwo estaba alabando Ifá*
*Él dijo que como su Babaláwo había dicho*
*Òfún escogió y lo escogió*
*Él lo escogió continuamente todavía que no era exhausto*
*Adivinación lanzada para Òrúnmìlà*
*Baba estaba llorando que él no tenía riqueza*
*Era el sacrificio que ellos le pidieron que realizara*
*Él escogió y lo escogió*
*Todavía no era exhausto*
*Es Ifá que posee riqueza maciza (voluminosa)*

***Òfún Ìká A***
*Ifá pé ká rúbọ fún araa wa ká sì rúbọ fún Obìnrin ẹni. Àtìyàwó àtọkọ ó jọ lo Ilé ayée wọn gbó ni. Gèlè tí ń bẹ lórí ìyàwó ẹ̀ lẹbọ.*

*Òrun ló kan àtàrí jìndùn jìndùn*
*A díá fún Bongágà obìnrin Ààtàn*
*Obìnrin Ààtàn ni Bongágà*
*Wọ́n níwọ Ààtàn rúbọ fún obìnriìn rẹ*
*Ti ò tîì dé ibì kankan tó gbé gèlè pẹ́npẹ́ sórí*
*Bílẹ̀ bá ti mọ́*
*Bongágà ó ti gbé adé lórí*
*Nígbà ti ó bàá e dọ̀sán*
*Ó ti rẹ̀*
*Wọ́n ní Ààtàn rúbọ*
*Kí obìnriìn rẹ̀ yìí ó ilè ayé pẹ́*
*Ààtàn ní kí Bongáà ó mú gèlè è orí ẹ̀ wá*
*Bongágà ò dáhùn*
*Àyìn éyìn ni Bongágà ń yin àwọn Babaláwo ẹ̀*
*Ó ní Òrun ló kan àtàrí jìndùn jìndùn*
*A díá fún Bongágà obìnrin Ààtàn*
*Ìgbà àì ṣẹbọ*
*Ìgbà àì tùèèrù*
*Ẹ̀ ẹ̀ ri bí Bongágà ti ń ba ikúú lọ.*

***Òfún Ìká A***
*Ifá le pide a esta persona que ofrezca el sacrificio para él y para su esposa tal que ellos dos disfrutarían la vida al final. El echarpe (faja, chalina) en la cabeza de la mujer es el sacrificio.*

*El sol se pone arriba y está chamuscando (quemar, abrasador)*
*Adivinación lanzada para Bongágà la esposa de Ààtàn*
*Bongágà se casó a Ààtàn*
*'Usted Ààtàn, realice el sacrificio para su esposa' ellos advirtieron*
*'Ella no es nada y ella está comportándose ostentosamente'*
*Una vez por la mañana*
*Bongágà se pondrían una corona como echarpe (faja, chalina)*
*Pero antes de la media tarde*
*Habría marchitado*
*'Usted Ààtàn, ofrezca sacrificio' ellos advirtieron de nuevo*
*'Tal que este su esposa se mantendría en la tierra mucho tiempo'*
*Ààtàn le pidió que trajera el echarpe (faja, chalina) en su cabeza*
*Bongágà se negó*
*Ella estaba alabando su Babaláwo tardíamente*
*Ella dijo 'El sol se pone arriba y está chamuscando'*
*Adivinación lanzada para Bongágà la esposa de Ààtàn*
*El mal de no realizar el sacrificio*
*El problema de no dar los premios (ganancias) prescritos*
*¿Puedan ustedes ver que Bongágà sigue, como la muerte se la lleva?*

***Òfún Ìká B***
*Ifá pé kí eléyìun ó rúbọ kí èèyàn ó mọ́ mọ́ọ fi òṣán ṣiṣẹ́ kí àwọn kan ó mọ́ fi òru bà á jẹ́. Ifá pé eléyìun dàra ṣùgbọ́n kó rúbọ àwọn tíí mọ́ọ fi òru rìn. Kí eléyìun ó sì mọ́ọ bọ̀ Òòsà fúnfún.*

*Òfún mọ̀le Ìká*
*Ìká mọ̀le Òfún*
*Òkùnkún mọ̀le òru*
*Fẹ́niféni a mọ̀le ọ̀gànjọ́*
*A díá fún Òòsàálá Ọ̀ṣẹ̀ẹ̀rẹ̀mọ̀gbò ti ń tọ̀run bọ̀ wálé ayé*
*Yóó mọ́ọ fòsán tún Ilé ayé ṣe*
*Wọ́n ní kó rúbọ kí wọ́n ó mọ́ mọ́ọ fòru bà á jẹ́*
*Gbogbo ire tèèyàn ó bàá ní láyé*
*Òòsàálá níí dá a ńgbà ìwásè*
*Yóó sọ féléyìí kó lájé*
*Tọ̀hún kó bímọ*
*Yóó sì rí bẹ́ẹ̀*
*Wọ́n ní kó rúbọ àwọn tí ń bọ̀ wálé ayé o*
*Òfún mọ̀le Ìká*
*Ìká mọ̀le Òfún*
*Òkùnkún mọ̀le òru*
*Fẹ́niféni a mọle ọ̀gànjọ́*
*A díá fún Òòsàálá Ọ̀ṣẹ̀ẹ̀rẹ̀mọ̀gbò*
*Ti ń tọ̀run bọ̀ wálé ayé*
*Yóó mọ́ọ fọ̀sán tún Ilé ayé ṣe*
*Wọ́n ní kó rúbọ kí wọ́n ó mọ́ mọ́ọ fòru bà á jẹ́*
